# Irúgbìn Òdì

Phoenix, Arizona, USA
Ọjọ Kejidinlogun, Osu Kinni, 1965

1 Mo ti yan asalẹ yii fun akori kukuru, tabi kika kukuru, ti Oluwa ba fẹ, lati fun wa ni itumọ rẹ, lati inu Matteu Mimọ 13:24 si 30. Lẹyinnaa, mo tun fẹ ka lati 36 de 40, ni isẹju melo kan. Bayi, Matteu Mimọ, ori 13, a o bẹrẹ pẹlu ẹsẹ 24, ni ori 13 ti Matteu Mimọ. Ẹ fi eti silẹ daradara si kika Ọrọ naa. Awọn ọrọ temi yoo kuna, sugbọn Tirẹ ko ni kuna.

*Owe miiran ni O pa fun wọn, wipe, Ijọba ọrun dabi ọkunrin kan ti o fun irugbin rere si oko rẹ:*

*Sugbọn nigbati o sun, ọta rẹ wá, ó sì gbin èpò si aarin alikama, o si ba tirẹ lọ.*

*Sugbọn nigbati èéhù rẹ̀ sọ jade, ti o sì so èso, nigbanaa ni awọn èpò farahan pẹlu.*

*Bẹẹni awọn ọmọ-ọdọ baale naa tọ ọ wa, wọn wi fun-un pe, Oluwa, irugbin rere ki iwọ fun sinu oko rẹ? Nibo ni o ha ti ni epo buburu?*

*O si wi fun wọn pe, Ọta ni o se eyi. Awọn ọmọ-ọdọ rẹ si bi I pe, iwọ ha fẹ ki a lọ … fa wọn tu kuro?*

*O si wipe, Bẹẹkọ; nigbati ẹyin ba n tu epo kuro, ki ẹyin ki o ma baa tu alikama pẹlu wọn,*

*Ẹ jẹ ki awọn mejeeji ki o dagba pọ titi di igba ikore: ni akoko ikore, emi yoo ran awọn olukore, Ẹ tete kọ kó epo jọ, ki ẹ di wọn ni ìtí lati fi ina sun wọn: sugbọn ẹ ko alikama sinu aba.*

2 Njẹ ẹ kiyesii, "Ẹ tete kọ ko awọn èpò jọ, ki ẹ si di wọn ni ìtí?" Bayi, ni kika eleyi, ohun àjèjì kan wá si ọkan mi nigbati mo joko ni ori Oke Catalina ni alẹ ijelo, ninu adura. Nigbanaa mo wa ronu wipe, nibo ni mo ti lee ri ọrọ ti mo lee lo fun eyi ti mo fẹ sọrọ le lori ni asalẹ yii?

Mo si lọ, mo ri ọrọ kan, òdì, nitorinaa mo mu iwe atumọ-ede, mo si wo ohun ti ọrọ òdì tumọ si. O si tumọ si "gbíngbin òdì," tabi "sise lòdì," gẹgẹbi Webster se sọ, "gbingbin òdì, ohun kan ti o yatọ," tabi "lilòdì si ohun ti o ti wà tẹlẹ." Nitorinaa mo ronu wipe akori ti asalẹ yii, n o pe e ni: "Irúgbìn Òdì." A si gbagbọ wipe Oluwa yoo bukun Ọrọ Rẹ̀ bi a se n lọ sinu rẹ.

3 A si tun mọ wipe Ó tumọ rẹ, ni ẹsẹ 36 ati 43, bi irugbin yii se dagba. Nigbati a si wa ninu rẹ, ẹ jẹ ki a ka iyẹn naa, ẹsẹ 36 titi de 43.

*Nigbati Jesu si ti ran ijọ eniyan lọ, o wọ inu ile lọ: awọn ọmọ ẹyin Rẹ si tọ ọ wa, wipe, Sọ idi owe epo ti oko fun wa.*

*O si dahun wi fun wọn pe, Ọmọ-eniyan ni ẹniti o furugbin rere;*

*Oko ni aye; irugbin rere ni awọn ọmọ ijọba; epo si ni awọn ọmọ ẹni buburu nni;*

*Ọta ti o fun wọn ni esu; igbẹyin aye ni ikore; awọn angẹli si ni awọn olukore.*

*Nitorinaa gẹgẹbi a tii ko epo jọ, ti a sii fi ina sun wọn, bẹẹni yoo ri ni igbẹyin aye.*

*Ọmọ-eniyan yoo ran awọn angẹli Rẹ, wọn o si ko gbogbo ohun ti o n mu ni kọse ni ijọba Rẹ kuro, ati awọn ti o n dẹsẹ;*

*Yoo si sọ wọn sinu ina ileru: nibẹ ni (ni ẹkun, tabi) ni ẹkun oun ipahinkeke yoo gbe wà.*

Nigbanaa ni awọn olododo yoo maa ran bi òòrùn ni ijọba Baba wọn. Ẹni ti o ba ni eti, ki o gbọ.

4 Jesu niyẹn ti o n fun ni ni itumọ owe naa, funra Rẹ, nitorinaa a ti wa mọ ohun ti itumọ rẹ jẹ. Bayi, bi a se n wọ inu eleyi lọ, niti fifun irugbin ati ti ikore, Oun tumọ rẹ bayi. Mo si gbagbọ wipe Jesu n pa owe yii ni ọjọ Tirẹ, sugbọn O nii lọkan wipe yoo jẹ opin aye, tabi opin igba, tii se ọjọ oni. Mo si gbagbọ wipe akori kekere yii ni asalẹ yii ba àkókò ti a n gbe inu rẹ mu, nitori Jesu sọ gbangba nibi yii wipe ikore yoo jẹ opin aye yii, wipe igba yẹn ni opin yoo de; kiko awọn alikama jọ, ati kiko awọn epo jọ lati fi ina sun wọn, ati lati ko awọn alikama sinu Ijọba. Mo si gbagbọ wipe bi o se ri niyi.

Iwe mimọ miiran si tun mu mi gbagbọ bayi, ti mo kọ silẹ nibi, ni Matteu 24:24, nibiti o ti sọ wipe, nigbati o n sọrọ nipa irugbin òdì, Jesu sọ wipe awọn mejeeji yoo sunmọ ara wọn to bẹẹ gẹẹ, ti yoo tan awọn ayanfẹ jẹ ti o ba see se. Wọn fẹrẹ jẹ nkan kannaa.

5 Ibomiran ninu Iwe Mimọ nibiti a kọ ọ si, wipe ojo n rọ sori olododo ati alaisododo.

Mo ranti iriri mi àkọ́kọ́ nigbati mo kọ́kọ́ de aarin awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ. Mo wà ni Mishawaka, Indiana. Mo si wà nibi ipagọ nla kan, gbọngan kan ti o da bi eleyi, nibiti awọn ara Ariwa ati Gusu ti pejọ pọ. Nitori ni awọn igba yẹn, ti ẹyamẹya, wọn nilati pade nibẹyẹn. Wọn jẹ awọn ilana nla meji ti awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ. N ko gbọ nipa wọn ri, bẹẹni n ko pade wọn ri. Igba akọkọ ti n o gbọ nipa ifedefọ niyẹn. Ni ẹyin awọn ijoko nibi ipagọ naa, emi ti kii se ọmọ ijọ laarin wọn, mo kan jẹ ọdọmọkunrin alufaa ijọ Onitẹbọmi, mo joko si ẹyin patapata. Mo si ranti wipe igba akọkọ ti mo gbọ ki ẹnikẹni fedefọ, n ko tilẹ mọ ohun ti o jẹ. Awọn okunrin meji yii joko siwaju, ọkan yoo fedefọ, ekeji yoo si tumọ ohun ti ọkunrin naa sọ. Ko buru, mo saa n wo inu Bibeli mi gidigidi, nibẹ ni mo si ti rii wipe o bá iwe mimọ mu. Ohun ti Iwe Mimọ, ani Ẹmi Mimọ yoo se gan-an niyẹn.

6 O dara, ni bii ọjọ kan lẹyin iyẹn. Lalẹ ọjọ yẹn, ọkan mi ru soke gan ni. Mo sun ninu oko agbado kan. N ko ni owo ti o to lati gba ibusun, iwọnba owo ti yoo gbe mi de ile ni mo ni, mo si ni awọn ounjẹ ipanu diẹ, ti o ti to bii ọjọ melo kan, ani ipanu fun ounjẹ owurọ mi. Wọn gba mi laaye lati ba wọn jẹun, sugbọn n ko ni owo lati fi lelẹ. Ni igba yẹn, akoko ti iyan mu ni, 1933, nitorinaa nkan le gan-an ni. Nitorinaa mo wa ronu bayi, “O dara, n o … n ko fẹ ba wọn jẹun, sugbọn mo fẹ mọ ohun ti wọn ni. Wọn ni nkankan ti emi ko ni.”

Nitorinaa, ni owurọ yẹn, wọn beere lọwọ mi, “Ki gbogbo oniwaasu wa si ori pẹpẹ, ki ẹ si fi ara yin han, ẹni ti ẹ jẹ, ibi ti ẹ ti wa.”

O dara, mo kan sọ pe, “William Branham, ajihinrere, Jeffersonville,” mo si joko. Nigbayẹn, emi ni oniwaasu ti ọjọ ori rẹ kere julọ lori pẹpẹ. Ni ọjọ keji, wọn pe mi si ori pẹpẹ lati sọrọ. Lẹyin ti mo si sọrọ tan, ah, a ni akoko ti o dara, nigbanaa mo bẹrẹ si pade orisirisi awọn eniyan, ti wọn n pe mi si awọn ijọ wọn. Leyin ti wọn….

7 Lẹyin iyẹn, mo ronu wipe, “Ka ni mo lee de ibi ti awọn ọkunrin meji yẹn wa ni, awọn ti o fedefọ ti wọn si tumọ rẹ!” Iyẹn n mu ọkan mi gbina, mo fẹ ẹ gan-an ni. O dara, bi mo se sọ fun yin lati ibẹrẹ, ẹbun kan ti a lee wọ inu rẹ. Se ẹ mọ, ẹbun ati ipe ko ni ironupiwada ninu, eniyan maa n ni i titi ọjọ aye eniyan ni, se ẹ rii, a bi wọn pẹlu eniyan ni, ti wọn ba jẹ ẹbun Ọlọrun. Nitorinaa, ni gbogbo igba, lati igba ti mo ti wà ni ọmọ kekere, ó maa n sẹlẹ si mi, awọn ti o mọ̀ mi ni gbogbo ọjọ aye mi, mọ wipe otitọ niyẹn. O dara, ti mo ba ronu, n ko mọ ohun ti o jẹ nigbanaa, lati pe e ni iran, n ko tilẹ mọ ohun ti o jẹ ni. Sugbọn mo ronu wipe, “Ti mo ba saa lee ba wọn sọrọ!” O dara, ẹmi ti o wà ninu ile naa da bii wipe Ẹmi Ọlọrun ni nitootọ.

Nitorinaa, mo ba ọkan ninu wọn sọrọ, mo si beere awọn ibeere diẹ lọwọ rẹ, oun si jẹ ojulowo Kristẹni. Kò sí iyemeji nipa rẹ, onigbagbọ tootọ ni ọkunrin yẹn. Ọkunrin keji, nigbati mo ba a sọrọ, ti mo ba tii pade agabagebe ri, ọkan ninu wọn niyẹn. Agabagebe gidi ni okunrin yẹn. Iyawo rẹ jẹ obinrin ti o ni irun pipọn, o si ni awọn ọmọ nipasẹ … ọmọ meji lati ọwọ obinrin kan ti o ni irun dudu. Mo wa ronu wipe, “O dara, kini o sẹlẹ bayi? Oun niyi, gbogbo rẹ daru mọ mi loju. Mo jẹ ẹni ti o gbagbọ wipe nkan gbọdọ lọ bi o se yẹ; o nilati jẹ Ọrọ naa, aijẹbẹẹ, ko tọ. Ẹmi yẹn si niyi, ọkan ninu wọn jẹ ojulowo, pẹlu iwoye mi, ekeji ko si dara rara, Ẹmi si n ba le awọn mejeeji. Bayi, bawo ni iyẹn sẹ lee ri bẹẹ?” O ya mi lẹnu.

8 Lẹyin ọdun meji, mo ti n gbadura ninu iho kan, nibiti mo ti lọ maa n gbadura. Ara mi kun fun eruku ninu iho naa, ni ọsan ọjọ kan, mo jade, mo gbe Bibeli mi le igi kan, afẹfẹ si si i si Heberu, ori kẹfa. Ti o sọ wipe, ni ikẹyin ọjọ, bi yoo se ri ti a ba subu kuro ninu otitọ, ti a si sọ ara wa di ọtun lòdì si ironupiwada, ko si ẹbọ fun ẹsẹ mọ, ati gẹgẹ bi ẹgun ati osusu, ti o sunmọ kikọ silẹ, opin ẹniti o wa fun ijona; sugbọn ojo n rọ sori ilẹ, leralera, lati bu omi rin-in, lati tun-un se; sugbọn ẹgun oun osusu ni a o kọ̀, sugbọn alikama ni a o ko jọ. Mo si ronu wipe, “O dara, afẹfẹ ni o kan si ibẹyẹn.” O dara, mo tun fi Bibeli yẹn silẹ lẹẹkan sii. Mo wa ronu wipe, “O dara, bayi n o kan….” afẹfẹ si tun wa, o tun si i silẹ. Iyẹn sẹlẹ ni igba mẹta. Mo wa ro o wipe, “O dara, bayi o, iyẹn se ajeji.”

Bi mo si se dide, mo ronu, “Oluwa, eese ti O fi si Bibeli yẹn fun mi lati ka ibẹyẹn, nigbati mo de ibi ẹgun oun osusu, eyi ti o sunmọ kikọ silẹ, opin ẹniti o wà fun ijona?” Mo ro o, “Eese ti O fi si iyẹn fun mi nibẹyẹn?” Mo wa wo ayika.

9 Bayi, awọn iran wọnyi maa n wa lai jẹ wipe mo se nkankan. Ọlọrun niyẹn. Se ẹ rii? Mo wo, mo si ri aye kan ti o n yi niwaju mi, mo si ri i wipe a ti ro gbogbo oko inu rẹ, a si ti kọ ebe si i. Ọkunrin kan wa ti o wọ asọ funfun, o n lọ kaakiri, o si n gbin alikama. Lẹyin ti o la aye ja; ọkunrin miiran tun wa ti o buru jai, oun si wọ asọ dudu, o si bẹrẹ si ju irugbin epo si inu rẹ. Awọn mejeeji si hu jade. Nigbati wọn se bẹẹ, orungbẹ n gbẹ awọn mejeeji, nitori wọn nilo ojo. O wa dabi ẹni wipe ọkọọkan wọn n gbadura, pẹlu idorikodo, “Oluwa, fi ojo ransẹ, fi ojo ransẹ.” Bẹẹni ikuuku bo ilẹ, ojo si rọ sori awọn mejeeji. Nigbati eleyi sẹlẹ, alikama kekere yẹn fo soke, o bẹrẹ si wipe, “Ẹ yin Oluwa! Ẹ yin Oluwa!” Bẹẹni epo kekere yẹn naa fo soke lẹgbẹ rẹ, o wipe, “Ẹ yin Oluwa! Ẹ yin Oluwa!”

Lẹyinnaa, a tumọ iran naa. Ojo n rọ sori olododo ati alaisododo. Ẹmi kannaa lee sọkalẹ sinu ipade isin, ki gbogbo eniyan si maa yọ ninu rẹ: ati agabagebe, ati Kristẹni, ati gbogbo eniyan. Bẹẹ gan-an ni. Sugbọn

kini? Nipa eso wọn ni a fi n mọ wọn. Se ẹ rii? Ọna kansoso ti a le gba mọ ọ niyẹn.

Se ẹ ri iyẹn bayi, niwọn igba ti o jẹ wipe epo, nigbamiran, maa n se afarawe alikama, wọn si jọ ara wọn de ibi wipe wọn yoo tan awọn ayanfẹ gan-an jẹ. Mo ro wipe a n gbe ni igba ti o yẹ, nigbati o yẹ ki a waasu lori awọn nkan wọnyi, ki a si sọrọ nipa wọn.

10 Ẹ kiyesii ni ẹsẹ 41, awọn mejeeji jọ ara wọn, wọn jọ ara wọn ni ikẹyin ọjọ́ de ibi wipe Oun ko se…. Oun ko lee gbẹkẹ le ijọ kan pato lati ya wọn sọtọ, boya, ijọ Eleto tabi ijọ Onitẹbọmi, tabi awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ, lati ya wọn sọtọ. O ni, "O ran awọn angẹli Rẹ lati ya wọn sọtọ." Angẹli kan n bọ wa lati mu iyasọtọ naa wa, iyasọtọ laarin ohun ti o tọ ati ohun ti kò tọ. Ko si si ẹni ti o lee se iyẹn bikose angẹli Oluwa. Oun ni yoo sọ eyi ti o tọ ati eyi ti kò tọ. Ọlọrun sọ wipe Oun yoo ran awọn angẹli Oun ni igba ikẹyin. Kii se awọn angẹli ni aarin meji, sugbọn awọn angẹli ni igba ikẹyin, wọn yoo si ko o jọ pọ. A mọ wipe akoko ikore ti de tan bayi. Bayi, angẹli tumọ si "ojisẹ." A si rii wipe awọn angẹli meje ti awọn ijọ meje ni o wà ni awọn igba ijọ.

Ẹ kiyesii ẹniti O sọ wipe awọn afurugbin naa jẹ, ati ohun ti irugbin naa jẹ pẹlu. Lakọkọ, Oun, Ọmọ Ọlọrun, ni afurugbin naa, ẹniti o jade lọ, ti o si n furugbin. Ọta kan si wá lẹyin Rẹ, eyi tii se esu, o si gbin irugbin òdì, lẹyin gbingbin Irugbin ti o tọ. Bayi, ẹyin ọrẹ, iyẹn ti sẹlẹ ni gbogbo igba, lati igba ti aye ti sẹ̀. Bẹẹ ni. Lati ibẹrẹ wa, o bere ohun kannaa.

11 Bayi o so pe, "Irugbin Ọlọrun, Oro Ọlọrun." Jesu sọ nibikan, wipe Ọrọ naa jẹ irugbin. Olukuluku irugbin ni yoo si mu iru ara rẹ jade. Bayi, ti Kristẹni, awọn ọmọ Ọlọrun, awọn ọmọ Ijọba ba ti di irugbin Ọlọrun, nigbanaa wọn nilati jẹ Ọrọ Ọlọrun, Ọrọ Ọlọrun ti a fi han ni iran ti wọn n gbe inu rẹ, fun Irugbin ti a se ileri rẹ fun ọjọ naa. Ọlọrun fi Ọrọ Rẹ fun ni lati ibẹrẹ, iran kọọkan ni o si ti ni Irugbin tirẹ, akoko tirẹ, awọn ileri tirẹ.

Bayi, nigbati Noa farahan, oun si ni iru Ọlọrun, Ọrọ Ọlọrun fun iran yẹn.

Nigbati Mose de, ko lee wa pẹlu isẹ-iransẹ iwaasu ti Noah, ko lee sisẹ, nitori oun ni Iru Ọlọrun ni akoko yẹn.

Njẹ nigba ti Kristi si de, ko lee wa pẹlu iran ti Noah tabi ti Mose; àkókò Tirẹ ni, fun wundia kan lati loyun, ati lati bi Ọmọkunrin kan, Oun ni yoo si jẹ Messiah.

12 Bayi, a ti la iran ti Luther kọja, ati iran Wesley (iran ijọ Eleto), ni gbogbo awọn iran, ati iran ti ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ, iran kọọkan ni a si fun ni ileri Ọrọ naa. Awọn eniyan iran yẹn, ti wọn fi Ọrọ ileri yẹn han, awọn ni Irugbin ti iran yẹn, gẹgẹbi ohun ti Jesu sọ nibi yii, "Awọn ni ọmọ Ijọba naa." Bẹẹ ni. Ifarahan Ẹmi Mimọ ti O n sisẹ nipasẹ awọn ọmọ Rẹ ni awọn Irugbin ti Ijọba naa ni iran yẹn.

Ẹ kiyesii, awọn epo ni ọta, Satani, ẹniti o gbin òdì, tabi irugbin òdì, oun ni o jẹbi sise ohun buburu yii. Satan gbin iru tirẹ lati atetekọse, nigbati Ọlọrun fi awọn eniyan Rẹ ti o kọkọ kore sori ilẹ aye. Sebi Adamu ko tii mọ wipe imọ otitọ kan wa nipa rere ati buburu, ko si tii wá sinu iyẹn sibẹ.

13 Sugbọn a rii, wipe Ọlọrun fun awọn ọmọ Rẹ ni Ọrọ Rẹ fun aabo wọn. A ko ni aabo miiran yatọ si Ọrọ Ọlọrun. Aabo wa niyẹn. Ko si àdó olóró, tabi ile ààbò kan, ko si awọn ibi ipamọ kan, ko si awọn Arizona tabi Kalifọnia, tabi ibikibi yoowu ti o jẹ; aabo kansoso ni a ni, oun ni Ọrọ naa. Ọrọ naa si di ara, O si n ba wa gbe, eyiti se Kristi Jesu, Oun nikan ni aabo wa. Ti a ba ti wa ninu Rẹ, a ni aabo.

A ko tilẹ ka ẹsẹ si onigbagbọ tootọ lọrun. Njẹ ẹ mọ iyẹn? Ẹniti a ti ipa Ọlọrun bi, kii dẹsẹ, ko lee dẹsẹ. Se ẹ rii? A ko tilẹ ka a rara. Ani Dafidi wipe, "Ibukun ni fun ọkunrin naa, ẹniti Ọlọrun ko ka ẹsẹ si lọrun." Nigbati o bá wà ninu Kristi, o kò ni ifẹ lati dẹsẹ. "Olujọsin ti a ti fọ mọ lẹẹkansoso, ko ni ifẹ ọkan fun ẹsẹ mọ," o ko fẹ ẹ rara. Bayi, loju aye, o lee jẹ ẹlẹsẹ; sugbọn loju Ọlọrun, o kii se ẹlẹsẹ, nitori o wà ninu Kristi. Bawo ni o se lee jẹ ẹlẹsẹ nigbati o wa ninu Ẹni alailẹsẹ, ẹniti o si wa ninu Rẹ nikan ni Ọlọrun n ri?

14 Àkókò ikore yii. Ni atetekọse, nigbati Ọlọrun gbin Irugbin Rẹ sori ilẹ aye, ti O si fi si inu ọkan awọn ọmọ Rẹ, ẹbi Rẹ, lati pa Ọrọ yẹn mọ, aabo kansoso ti wọn ni niyẹn, ki wọn pa Ọrọ yẹn mọ! Ọta si wá, o mu aabo yẹn kuro, nipa gbingbin irugbin òdì, eyi ti o lòdì si Ọrọ Ọlọrun. Ti iyẹn ba jẹ òdì ni atetekọse, o si jẹ bẹẹ…. Ohunkohun ti o ba fi ohun kan kun Ọrọ Ọlọrun, o si jẹ irugbin òdì! Emi ko bikita ibi ti o ti wa, ti o ba ti inu ẹgbẹ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ wa, ti o ba ti ọdọ awọn ologun wa, ti o ba ti ọdọ awọn oloselu wa, ohunkohun ti o ba lòdì si Ọrọ Ọlọrun, irugbin òdì ni!

Nigbati ẹnikan ba dide, ti o sọ wipe oniwaasu ihinrere ni oun, ti o si sọ wipe ọjọ isẹ-iyanu ti kọja, irugbin òdì niyẹn. Nigbati ẹnikan ba dide, ti o sọ wipe iransẹ ni oun, olusọ-aguntan ijọ kan nibikan, ti ko si gbagbọ wipe Jesu Kristi jẹ ọkannaa ni gbogbo ọna (yatọ si ara Rẹ ti a le foju ri), ọkannaa lana, loni ati titi laelae, irugbin òdì niyẹn. Nigbati o ba sọ wipe awọn isẹ-iyanu ati igba awọn aposteli ti kọja, irugbin òdì niyẹn. Nigbati wọn ba sọ wipe ko si iwosan lai lo oogun, irugbin òdì niyen. Aye si kun fun iyen. O pọ ju alikama lọ, o si n fun-un pa.

15 A kiyesii wipe ẹniti o kọkọ gbin irugbin òdì ni a pe ni “esu,” a si mọ wipe o wà ni Gẹnẹsisi 1. Bayi a ti rii, wipe ninu iwe Matteu, ni ori kẹtala, Jesu si pe ohunkohun ti o lòdì si Ọrọ Rẹ ni esu. Ati ni ọdun 1965 yii, ohunkohun ti o ba gbin òdì, lòdì si Ọrọ Ọlọrun ti a kọ, tabi ti o fi itumọ ikọọkọ si i, o jẹ irugbin òdì. Ọlọrun ko ni bu ọla fun-un. Ko lee se e. Ko lee dapọ. Dajudaju, ko lee se e. O dabi irugbin mustadi; ko lee dapọ mọ ohun miiran, e ko lee se alupayida rẹ, o nilati jẹ ojulowo. Irugbin òdì!

16 Bayi, a rii, nigbati Ọlọrun gbin irugbin Rẹ ni ọgba Edẹni, a rii wipe o mu Abẹli jade wa. Sugbọn nigbati Satani gbin irugbin òdì rẹ, o mu Kaini jade wa. Ọkan mu olododo jade wa; ọkan mu alaisododo jade wa. Nitori Eefa fi eti si ọrọ òdì, ti o lòdì si Ọrọ Ọlọrun, o si mu ki ẹsẹ maa tẹsiwaju lati ibẹyẹn, o si ti n tẹsiwaju lati igba naa wa. A ko si lee mu gbogbo rẹ kuro, ayafi ti awọn angẹli ba wa lati pin wọn niya, ti Ọlọrun si ko awọn ọmọ Rẹ lọ si Ijọba naa, a o si sun awọn epo ninu ina. E kiyesi awọn ajara mejeeji yẹn.

Ti a ba ni akoko sii lori akori ọrọ yii, sugbọn a o kan sọ awọn koko ibẹ ni, ki a baa lee tete bẹrẹ adura gbigba fun awọn alaisan ni isẹju meko kan sii.

17 Ẹ kiyesii, awọn irugbin wọnyi jọ n dagba papọ gẹgẹbi Ọlọrun se sọ nihin ni ori kẹtala, ti ibi ti a ka ni asalẹ yii, ti Matteu, “Ẹ jẹ ki wọn maa dagba papọ.” Bayi, Kaini lọ si ile Nọdi, o wa iyawo kan fun ara rẹ, o si fẹ ẹ; a si pa Abẹli, Ọlọrun si gbe Seti dide lati rọpo rẹ. Awọn iran naa si n tẹsiwaju, laarin rere ati buburu. Bayi, a kiyesii wipe wọn n pejọ pọ, olukuluku wọn, lati igba de igba, Ọlọrun si nilati…. O buru de ibi wipe Ọlọrun nilati pa wọn run.

Sugbọn nikẹyin, wọn jade wa titi ti awọn irugbin mejeeji, irugbin òdì ati irugbin Ọlọrun, fi so ojulowo eso wọn, iyẹn si yọri si Judasi Iskariọti ati Jesu Kristi. Nitori, Oun ni irugbin Ọlọrun, Oun ni ibẹrẹ isẹda Ọlọrun, ko yatọ si Ọlọrun. A si bi Judasi Iskariọti ni ọmọ ègbé, o ti ọrun apaadi wá, o si pada si ọrun apaadi. Jesu Kristi jẹ Ọmọ Ọlọrun, Ọrọ Ọlọrun ti a fihan. Judasi Iskariọti, ninu òdì rẹ, jẹ irugbin esu, o wa si aye fun ẹtan; gẹgẹbi o se ri ni ibẹrẹ, Kaini, baba rẹ atijọ.

18 Judasi kan n fi ijọ boju ni. Ko jẹ olootọ rara, ko ni igbagbọ nitootọ (ki ba ti da Jesu). Sugbọn, se ẹ rii, o gbin irugbin òdì yẹn. O ro wipe oun lee ba aye se ọrẹ, mamoni, ki oun si tun jẹ ọrẹ pẹlu Jesu, sugbọn o ti pẹ ju fun-un lati se ohunkohun nipa rẹ. Nigbati wakati naa de, nigbati o se ohun buburu yii, o ti re aala kọja laarin lilọ siwaju ati pipada sẹyin. O nilati tẹsiwaju ni ọna ti o rin, gẹgẹbi ẹlẹtan. O gbin irugbin òdì, o gbiyanju lati ri ojurere awọn ijọ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ ni igba yẹn, pẹlu awọn Farisi ati Sadusi. O ro wipe oun yoo pa owo diẹ, ati wipe oun yoo jẹ olokiki laarin awọn eniyan. Njẹ iyẹn kọ́ ni o n jẹ ki ọpọlọpọ eniyan bọ sinu òdì yen, wọn n gbiyanju lati wa ojurere eniyan! Ẹ jẹ ki a wa ojurere Ọlọrun, kii se ti eniyan. Sugbọn ohun ti Judasi se niyẹn nigbati awọn òdì wọnyi so eso jade ninu rẹ.

19 A si mọ wipe Jesu ni Ọrọ naa, Johannu Mimọ 1, sọ pe, “Ni atetekọse ni Ọrọ wa, Ọrọ wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa … Ọrọ naa si di ara, O si n ba wa gbe ihin.” Nigbanaa, Ọrọ naa jẹ Irugbin, Irugbin naa si di ara, o si n ba wa gbe.

Ti Judasi ba jẹ irugbin ti ọta ati ti òdì, oun naa di ara o si n gbe aarin wa ninu ẹni ti Judasi Iskariọti jẹ. Ko fi igba kan ni igbagbọ tootọ. O ni ohun ti o ro wipe o jẹ igbagbọ. Ohun kan ni ki eniyan ni igbagbọ; ọtọ si ni afarawe igbagbọ.

Igbagbọ Ọlọrun tootọ yoo gbagbọ ninu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa, ki yoo fi ohunkohun kun-un laelae. Bibeli sọ fun wa wipe ti a ba fi ọrọ kan kun-un, tabi a mu ọrọ kan kuro, a o mu ipin wa kuro ninu iwe iye, Ifihan 22:18, ori ti o gbẹyin.

20 Ni atetekọse, iwe akọkọ ninu Bibeli, Ọlọrun sọ fun wọn wipe wọn ko gbọdọ sẹ ẹyọ kan ninu ọrọ yẹn. Wọn gbọdọ pa gbogbo ọrọ naa mọ. Wọn gbọdọ maa gbe nipa Ọrọ yẹn. Jesu, ni aarin Iwe naa, wa, O si sọ wipe … ni iran Tirẹ, O ni, “Eniyan ki yoo wa laaye nipa akara nikan, sugbọn nipa gbogbo Ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade.” Ati ni ipari iran Ifihan, o sọtẹlẹ fun wa, wipe “Ẹnikẹni ti o ba mu ọrọ kan kuro ninu Iwe naa, tabi ti o fi ọrọ kan kun-un, a o mu ipin rẹ kuro ninu iwe iye.”

Nitorinaa, ko lee si bojuboju kan nibẹ, bikose ojulowo Ọrọ Ọlọrun ti ko ni abula! Awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun niyẹn, awọn ti a ko bi nipa ifẹ eniyan, tabi nipa bibọ ọwọ, tabi nipa ilana iribọmi kan; sugbọn ti a bi ninu Ẹmi Ọlọrun, nipa Ẹmi Mimọ, ti Ọrọ naa si n fi ara Rẹ han ninu wọn. Awọn irugbin Ọlọrun tootọ niyẹn!

21 Ọta n darapọ mọ ijọ, yoo si jẹ olootọ ninu ẹkọ adamọ tabi nkan miiran. Sugbọn iyẹn kọ ni…. Òdì niyẹn, ohunkohun ti o ba tako ojulowo otitọ Ọrọ Ọlọrun taara yẹn.

Bawo ni a si se mọ? A sọ pe, “O dara, se o ni ẹtọ lati tumọ rẹ?” Rara, sa! Ko si ẹni ti o ni ẹtọ lati tumọ Ọrọ Ọlọrun. Oun ni olutumọ ara Rẹ. O se ileri rẹ, lẹyinnaa O si se e, itumọ rẹ niyẹn. Nigbati O se ileri rẹ, lẹyinnaa ti O mu u sẹ, itumọ rẹ niyẹn. Ohunkohun ti o ba lòdì si Ọrọ Ọlọrun, jẹ òdì! Dajudaju!

Bayi, gẹgẹbi mo se sọ, Judasi ko ni igbagbọ tootọ. O ni ohun ti o jẹ afarawe igbagbọ. Ó ni igbagbọ kan ti o fi ro wipe Ọmọ Ọlọrun niyẹn, sugbọn ko mọ wipe Ọmọ Ọlọrun niyẹn. Ki ba ti se e. Ẹni ti o ba si gba ibọde wipe Ọrọ Ọlọrun yii kii se otitọ, o ni igbagbọ afarawe. Ojulowo iransẹ Ọlọrun so mọ Ọrọ yẹn.

22 Ni alẹ ọjọ melo kan sẹyin, iransẹ Ọlọrun kan ni Arizona, ti ile iwe nla kan ti o lokiki ni ilu yii, tọ mi wa, o si wipe, "Mo fẹ tọ ọ sọna lori nkankan (mo ni…) nigbati o ba ri aaye."

Mo ni, "Aaye ti o dara ju ti mo mo niyi. Maa bo."

O si wa, o ni, "Ọgbẹni Branham, o n gbiyanju…." O ni, "Mo gbagbọ wipe o jẹ olootọ, o si jẹ olododo, sugbọn o n gbiyanju lati fi ẹkọ awọn aposteli han fun aye." O ni, "Igba awọn aposteli ti kọja lọ pẹlu awọn aposteli."

Mo ni, "Ohun akọkọ ti mo fẹ beere lọwọ rẹ, arakunrin mi, ni wipe, se o gbagbọ wipe gbogbo Ọrọ Ọlọrun ni o ni imisi?"

O ni, "Bẹẹ ni, sa, mo gbagbọ dajudaju."

Mo ni, "Nigbanaa, se iwọ yoo fi han mi ninu Ọrọ naa, ibiti igba awọn aposteli ti duro? Bayi, iwọ fi ibi ti o wà han mi, n o gbagbọ pẹlu rẹ." Mo si sọ wipe, "Ẹni ti o kọ iwe awọn aposteli, ẹniti o ni kọkọrọ si Ijọba naa, ni ọjọ Pentikọsti, nigbati a mu igba awọn aposteli wọle wa, wọn ni, 'Eyin ara atị ọre, kini a lee se ki a lee ni igbala?' O ni, 'Ẹ ronupiwada, olukuluku yin, ki a si ri yin bọ omi ni orukọ Jesu Kristi, fun imukuro ẹsẹ yin, ẹyin o si gba ẹbun Ẹmi Mimọ, nitori ileri naa wa fun yin, ati fun awọn ọmọ yin, ati fun awọn ti o jinna rere, ani iye awọn ti Oluwa Ọlọrun wa yoo pe.' Bayi, bawo ni Ọrọ naa se lee tako ara rẹ?"

Ọkunrin naa sọ wipe, "Otutu n pa mi gidi ni asalẹ yii."

Mo ni, "Emi naa ro bẹẹ." Se ẹ rii?

Bayi, ẹ sọ fun mi, se Ọlọrun si n pe? Ti Ọlọrun ba si n pe, a jẹ wipe igba awọn aposteli si wa sibẹ. Dajudaju! Iye awọn ti Oluwa Ọlọrun wa yoo pe, ti yoo si pe, iye awọn ti yoo pe, yoo jẹ igba awọn aposteli sibẹ, nitori Jesu Kristi jẹ ọkannaa lana, loni, ati titi laelae.

23 Bayi, a rii loni wipe wọn ti gbin òdì yii ni gbogbo awọn iran. Ti o ba see se lati pari rẹ laarin isẹju mẹwa tabi mẹẹdogun, n o se e, sugbọn ko see se. Ni gbogbo awọn iran…. Gbogbo wa, o fẹrẹ jẹ wipe gbogbo wa ni o n ka Bibeli. Ati ni bayi, bi igba ti Jesu wa, O si ri òdì na, ti o se lòdì. Oun ni Ọrọ ti o farahan. Oun ni itumọ Ọrọ Ọlọrun, nitori O wipe, "Ẹ wa inu Iwe Mimọ, ninu wọn ni ẹ ro wipe ẹ ti ni iye ainipẹkun, awọn ni o si n jẹri Mi." Bi o se ri niyẹn. Oun ni itumọ Ọrọ naa. Ati gbogbo awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin Ọlọrun ti a ti tun bi ni iran yii ni itumọ Ọrọ naa. Ẹyin ni episteli ti a kọ, ti gbogbo eniyan n ka. Bẹẹni.

Ẹ kiyesii, O ni, "Lasan ni wọn n sin mi, wọn n fi òdì kọ ni ni ẹkọ. Lasan ni wọn n sin mi, wọn n fi òdì kọ ni ni ẹkọ, ẹkọ awọn eniyan, ẹkọ adamọ awọn eniyan, wọn n fi iyẹn kọ ni bii Ọrọ Ọlọrun, nigbati o jẹ wipe ko ni nkankan se pẹlu Ọrọ Ọlọrun."

24 Ẹ woo, iran kọọkan ni o ni iru awọn bẹẹ, gbogbo iran ni o se bẹẹ, tiwa ko si yatọ. A ni iru nkan kannaa, ti iran yii pọ ju apapọ gbogbo awọn iran ti o ti kọja lọ, nitori eyi ni opin itan aye. Eleyi ni òdì ti o ga ju ti o tii wa lori ilẹ aye, o wa lori ilẹ aye loni. Òdì ní awọn iran ti o kọja, fa wọn kuro lọdọ Ọlọrun alaaye tootọ, si orisa. Loni, Jesu sọ ni Matteu 24:24 wipe yoo jọ ara wọn titi ti yoo fi tan awọn ayanfẹ jẹ ti o ba see se. Ti a ba n sọrọ nipa òdì! Ah, ẹtan gidi ni. Satani wa laarin awọn eniyan, o si je ẹlẹkọ ẹsin, o ti gba oye dokita ninu ẹkọ ẹsin, o fẹrẹ le kọ ni ni Ọrọ yen ni pipe. Jesu sọ bẹẹ. Sugbọn ẹ woo finni-finni, ibi kan wa ti wọn yoo ti sọ pe, "O dara bayi, iyẹn ko wa fun eyi…." Ah, bẹẹ ni, o wa fun-un pẹlu, se ẹ rii, nitori Ọlọrun sọ bẹẹ.

25 Ẹ wo ohun ti o se. Iru òdì kan yii naa ni o mu ibinu Ọlọrun wa ni igba Noah, nigbati Ọlọrun ran wolii Rẹ jade ti o si waasu bi ina, o pe awọn eniyan wa si ironupiwada, awọn ti o jẹ iru òdì si ba omi lọ. Ki ni Satani wa se? O tun gba ẹyin wa, ninu Hamu, o tun bẹrẹ lati maa gbin. Bi o se ri gan-an niyẹn.

Mose wa, wolii nla nni, lati ko awọn ọmọ Israeli jade kuro ninu aginju. Ki lo sẹlẹ? Mose, wolii Ọlọrun nla nni, o mu otitọ gidi tọ wọn wa, otitọ ti a fi idi rẹ mulẹ. O ti ba Ọlọrun pade. Ọlọrun fihan wipe o ti ba Oun pade. Awọn eniyan igba yẹn, awọn alufaa yẹn, wọn ni ẹsin tiwọn, awọn ilana, awọn etutu ati ohun gbogbo, sugbọn Mose duro gẹgẹbi ifihan itumọ Ọrọ naa. Ẹ mase gbagbe iyẹn! Mose ni itumọ ileri Rẹ. O sọ pe, Oun yoo se e; Oun ni itumọ Ọlọrun.

26 Ki lo sẹlẹ? Ijọ sẹ̀sẹ̀ n jade kuro ni Egipti ni, o sẹsẹ duro lori ẹsẹ̀ rẹ̀ fun ọjọ diẹ, ki lo si sẹlẹ? Satani wá pẹlu irú òdì rẹ ninu ẹni kan, Kaini keji, eyi tii ise Balamu, o si gbin irú òdì si aarin wọn. A mọ wipe otitọ niyẹn. Balaamu yẹn - ẹ̀kọ́ Balaamu, wipe ọ̀kan naa ni gbogbo wa, Ọlọrun kannaa ti ẹ n sin ni awa naa n sin. Ni pataki, otitọ ni, nitori o se irubọ ti Ọlọrun naa se; àgbò meje, akọ maluu meje lori pẹpẹ meje, o si gbadura si

Ọlọrun kannaa ni pípé bi Mose ti se ni aginju, bakannaa ngan-an. Sugbọn wọn kii se nkan kannaa! Eleyi n se apẹẹrẹ fun wa, ohun ti yoo sẹlẹ. Kaini ni a tun ri nibẹyẹn, ti o farahan ninu Balaamu. A si ri Ọlọrun nibẹyẹn pẹlu, ti o farahan ninu Mose, ti o n tumọ ọrọ Rẹ nipasẹ eniyan, O n so ara Rẹ di mimọ, ati ileri rẹ̀, nipasẹ eniyan kan. Irú òdì naa si dide.

Bẹẹ naa ni o se ni igba Judasi, o wa sibẹ pẹlu irú òdì rẹ.

27 Ẹ si ranti, ẹ̀sẹ̀ yii ti awọn eniyan yẹn gbagbọ, wipe ọ̀kannaa ni gbogbo wa, Ọlọrun kannaa ni a n sin, o yẹ ki gbogbo wa wa ninu ijọ kannaa, o yẹ ki a jẹ eniyan kannaa. A ko dari ẹ̀sẹ̀ yẹn ji Israẹli! Jesu funra Rẹ sọ pe, gbogbo wọn ni o kú!

Wọn sègbé, ayafi awọn mẹta ninu wọn, awọn yẹn si ni awọn ti o di ileri Ọlọrun mu, ti wọn si gba a gbọ. Nigbati awọn alailera sọ wipe, “A ko lee gba ilẹ naa, o ti pọ ju fun wa,” ati bẹẹ bẹẹ lọ; Kalẹbu ati Josua pa awọn eniyan naa lẹnu mọ, wọn si wipe, “A to bẹẹ, a ju bẹẹ lọ, lati gba a, nitori Ọlọrun se ileri rẹ fun wa! N ko bikita ohun ti atako naa jẹ!”

A si tun lee waasu iwosan lai lo oogun, ati baptisimu Ẹmi Mimọ, ki a si tun ni agbara Ọlọrun lati yà wá kuro ninu awọn nkan ti aye. Ọlọrun sọ bẹẹ! Igba awọn aposteli koi tii dáwọ́ duro, ko si ni dáwọ́ duro, o n tẹsiwaju.

Bayi, a ri afurugbin òdì atijọ nni. Ẹ si ranti, a ko dari ẹ̀sẹ̀ yẹn ji. Bayi, arakunrin, ti a ko ba dari ji wọn nigba yẹn, àkókò yi nkọ, nigbati ojulowo irugbin ti gbogbo awọn iran wa n papọ bayi?

28 Ẹ kiyesi nkan nla yi ti Balaamu se, o n tẹsiwaju ati siwaju, nikẹyin o pari si bibọ Judasi Iskariọtu, ati Jesu. Ki ni? Judasi ati Jesu jẹ aworan Kaini ati Abẹli. Nitori, bi Judasi se jẹ ẹlẹsin, bẹẹ naa ni Kaini jẹ ẹlẹsin. Kaini se pẹpẹ kan, o se irubọ, o sin Ọlọrun, o jẹ olootọ ninu rẹ gẹgẹbi ẹnikeji naa se jẹ. Sugbọn, njẹ ẹ rii, ko ni ifihan ohun ti Ọrọ naa jẹ. O ro wipe èso kan tabi omiran ni Adamu ati Eefa jẹ. Sugbọn Abẹli, nipa ifihan, mọ wipe iyẹn kuna; ẹ̀jẹ̀ ni o lé wọn jade, o si fi ọdọ-aguntan kan rubọ. Ọlọrun si jẹri wipe ọrẹ rẹ̀ tọna. Nigbanaa o se ilara, o si gbiyanju lati pa arakunrin rẹ. Bi o si se pa arakunrin rẹ ni ori pẹpẹ kannaa nibiti ẹbọ rẹ̀ kú sí, ọdọ-aguntan naa kú lori pẹpẹ naa, bẹẹ naa ni Judasi da Jesu Kristi lori pẹpẹ Ọlọrun, o si pa A gẹgẹbi Kaini se pa Abẹli. Nitori Kaini ni irugbin òdì.

Bẹẹ naa ni Balaamu, alagbase wolii, ẹni ti o yẹ ki o mọ otitọ. Ọlọrun si kilọ fun-un nipa isẹ-ami ati isẹ-iyanu, to bẹẹ ti ibakasiẹ n sọrọ ni èdè aimọ, sibẹ o tẹsiwaju bakannaa. A bi i lati jẹ afurugbin òdì.

29 Ti Jesu ba si sọtẹlẹ wipe iran yii yoo pari si òdì ti o ga julọ ti o tii wa ri, igba Ijọ Laodikea, ko-gbona ko-tutu, ti wọn fi lé Oun jade kuro ninu ijọ, bawo ni o se lee jẹ ohun miiran yatọ si iyẹn? Òdì! Dajudaju, bẹẹ ni o ri. O pari ni iran yẹn.

Kaini ati Abẹli si tun niyẹn ni Kalfari.

Ẹ kiyesii bayi, bi o ti ri tẹlẹ, kété ti Jesu lọ, ti Ó lọ si Ọrun, a ran Ẹmi Mimọ pada wa. Iru naa niyẹn, ẹni ti o n fun Ọrọ naa ni ìyè, bi a se sọ ni alẹ ana. Oun ni o n sọ Ọrọ naa di aaye. Sọ di aaye ni “mimu wa si aaye.” Ẹmi Mimọ tootọ maa n mu Ọrọ ti o jẹ wa si iye ni. Ko ni mu ẹkọ-adamọ wa laaye, ko lee se e, nitori ko ni nkankan se pẹlu ẹko adamọ. O jẹ iye ti Ọrọ Ọlọrun, nitori Ọlọrun ni, se ẹ rii. O si n sọ ara naa di aaye.

30 Ẹ kiyesii bayi, bi wọn se se. Njẹ, gẹgẹbi Bibeli se sọ, Johannu si ba awọn ọmọ rẹ sọrọ, o ni, “Ẹyin ọmọde, ẹ ti gbọ nipa asòdì si kristi ti o n bọ wa si aye,” o ni, “eyi ti o ti wa ninu aye bayi, o si n sisẹ ninu awọn ọmọ alaigbọran.” Bayi, iyẹn jẹ bii ọgbọn ọdun lẹyin ti Ẹmi Mimọ ti wá. A rii wipe nigbati Ẹmi Mimọ wá, ojulowo Irugbin, ojulowo Ẹni ti o n fun irugbin naa ni iye, a ri wipe irú òdì naa tun wá. Ẹ si kiyesii, o n tẹsiwaju bẹẹ.

Ogidi Ọrọ naa ni a ti fi han, awọn wolii atijọ nni ti fi Ọrọ Ọlọrun han wipe o jẹ otitọ bi wọn se n lọ. Ti ẹnikẹni ba ti ka iwe “Igbimọ ti Nikia,” tabi “Igbimọ Saaju Nikia,” ọjọ mẹẹdogun ti o le, ti wọn fi se òsèlú yẹn, nigbati awọn ara Roomu nibẹ fẹẹ sọ ijọ naa di ijọ ẹlẹkọ adamọ. Awọn wolii wa, wọn fi awọ aguntan bora, wọn n jẹ ewébè, wọn si duro fun Ọrọ naa! Sugbọn kini o se? O nilati da bii Kaini, o nilati da bii Abẹli, ọkan nilati ku. Dajudaju, o se bẹẹ. Ọrọ naa si sọ ipá rẹ nù laarin awọn eniyan naa, gbogbo wọn si fi ìbò mu Ọrọ naa kuro, wọn si gba ẹkọ adamọ ati òdì ti ijọ Katoliiki àkọ́kọ́. Wọn fi póòpù kun-un, wọn fi bísóòbù kun-un, wọn fi eleyi, ati iyẹn, ati omiran kun-un. Wọn mu itumọ tootọ ti Peteru kuro, ati ti Maria ati gbogbo awọn ti o kù; wọn si yá ère, wọn si sọ ẹ̀sìn ti wọn pe ni ẹ̀sìn Kristẹni di asa keferi lasan. Ki ni? Irugbin òdì! Fun igba akọkọ, wọn fi ọgbọn eniyan gbe ijọ kan kalẹ lori ile aye. Ki ni? Irugbin òdì yẹn ti o bẹrẹ, fifi ohun kan kun-un, tabi mimu kuro.

31 Ta ni o gbọ ọ ri, ninu Bibeli, wipe a ko gbọdọ jẹ ẹran ni ọjọ Ẹti? Ta ni o gbọ o ri, ninu Bibeli, wipe ki a bu omi wọn eniyan, dipo riri eniyan bọ inu omi? Ta ni o gbọ nkan wọnyẹn ri, kika “Maria Mimọ,” tabi nkan kan? Ta ni o gbọ ibajẹ awọn ijọ ti o tako Katoliiki yii, pẹlu? Ìkòkò ko lee sọ wipe ara abọ idana dudu. Bẹẹ ni! Ẹniti o ba jẹbi ofin kan, o ti jẹbi gbogbo rẹ! Ta ni o gbọ ọ ri wipe Ọlọrun ni nkankan se pẹlu ijọ ti a fi ọgbọn eniyan gbe

kalẹ? Ẹ fi han mi, igba kan ti ijọ kan di igbekalẹ eniyan, ti o tun pada dide wà láàyè ri! Wọn n ku lẹsẹkẹsẹ, wọn kò sí tun dide mọ laelae! Àkókò ti to ti nkankan nilati sẹlẹ, àkókò ti to fun Ọlọrun lati sisẹ. Wọn n pa ipá rẹ laarin awọn eniyan.

Ohun kannaa ni wọn ti se loni. Wọn n pa ipá ti o ni, wọn ni, "Ah, awọn ẹgbẹ gbara yilẹ mimọ yẹn, ko si nkankan nipa wọn." Ki ni, irú òdì ni! Ba Ọrọ naa pade lojukoju ki o si wo ohun ti ó jẹ, wo o ti Ọlọrun ba tumọ Ọrọ ara Rẹ. Ọlọrun lee gbe ọmọ dide fun Abrahamu lati inu okuta wọnyi. Amin.

32 A ti fi Ọrọ naa han gidigidi nipasẹ awọn Kristẹni akọkọ, bi Ọlọrun se gba wọn ninu ohun gbogbo, ati awọn arun, wọn si ni awọn wolii, wọn si sọrọ ni èdè miiran, wọn tumọ rẹ, wọn si jisẹ ti a fihan wipe o jẹ otitọ ni gbogbo igba. Sugbọn pẹlu gbogbo Ọrọ ti a fihan yen, awọn eniyan fi ibo gbe e jade, wọn si fi ibo yan ijọ ẹlẹkọ-adamọ. Ìyá gbogbo awọn ijọ aye niyẹn.

Awọn mejeeji ti dagba bayi. Wọn tun ti n so eso. Ó kú, sugbọn o tun gbilẹ ni ọjọ Luther, gẹgẹbi a se mọ nipa iwaasu ti a ti waasu tẹlẹ, nihin ni igba ounjẹ owurọ. O bú jade ni ọjọ Luther. Kini wọn se bayi? Kete ti ẹni nla yẹn kú, wọn se ijọ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ.

O bú jade. Lẹẹkan sii ni ọjọ John Wesley, nigbati awọn Anglican, pẹlu gbogbo ẹkọ ààbò ainipẹkun wọn ati ohun gbogbo, o so wọn papọ de ibi ti o jẹ wipe gbogbo rẹ ti gbilẹ kaakiri agbaye, ki ni o si sẹlẹ? Ọlọrun gbe ọkunrin kan dide ti orukọ rẹ n jẹ John Wesley, o si pa gbogbo nkan yẹn. Kete ti oun naa kú, oun ati Asbury ati awọn ti o kù, ki lo sẹlẹ? Wọn tun fi ọgbọn eniyan ko ara wọn jọ, bayi, a ti ni oniruuru ijọ Eleto. Lẹyinnaa ni awọn miiran tun wá, Alexander Campbell, John Smith, ati awọn ti o kù.

33 Nikẹyin, awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ jade, wọn jade kuro ninu gbogbo rẹ. Ki lo sẹlẹ lẹyinnaa? Wọn sare nitootọ, sugbọn ki ni o n di yin lọwọ? Ẹ tun pada si inu ẹrẹ̀ ti ẹ ti jade kuro, ẹ pada taara sinu ẹrẹ̀ kannaa, ẹ pada sinu òdì lati dá ẹgbẹ eniyan kalẹ, ẹ nilati gba ìbọ̀dè ti Ọrọ naa. Gbogbo igba ti Ọlọrun ba si fi ohun titun ransẹ, ẹ ko lee gba a. Bẹẹ ni! Iru òdì lẹẹkan sii! Ẹ si kiyesii, bi mo se sọ ni ijelo, eehu kekere ti o kọkọ jade lati inu gbòngbò yẹn, oun lo dagba di ewe ati irukẹrẹ, lẹyinnaa o tun pada si inu pòpórò, o si jade. Èèpo alikama kekere yẹn da bii alikama funra rẹ, a si ro wipe oun ni, sugbọn nigbati ẹ si i, ko si hóró ọkà nibẹ rara. O kan jẹ alabaru lati mu ọka dagba ni, oun naa si kú pẹlu, ìyè si jade kuro ninu rẹ, o si wọ inu hóró ọkà lọ. Ẹ kiyesii, wọn si pe awọn ijọ ti o gbin…

34 A rii loni wipe awọn ti o pe ara wọn ni ijọ, titi ti o fi kan ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ, a jade lo, a ko lee ni itẹlọrun, a nilati da ẹgbẹ tiwa silẹ. Orisirisi ni ó n hù jade, a nilati ni eleyi, a nilati ni eleyi, a nilati ni ẹgbẹ miiran. Ẹnikan yoo si dide, yoo wipe, "O n bọ lori ikuuku funfun." Omiran wipe, "Uh-huh, O n bọ lori ẹsin funfun." O dara, a o da ẹgbẹ meji silẹ." Se ẹ ri, ki ni? Gbigbin òdì! Nigba ti Ó bá de, ohun yoowu ti o jẹ, Oun yoo tumọ Ọrọ ara Rẹ nigbati O ba de. Ẹ jẹ ki a duro di igba yẹn. Mu … Ti a ba n sọrọ nipa iyẹn, a ko tilẹ ni mu ẹnu ba iwaasu oni. Wọn n fi igba gbogbo tọka si ohun ti Ọlọrun yoo se, tabi ohun ti O ti se, won si n se ainaani ohun ti O n se lọwọlọwọ. Bi a se n mu òdì wọ inu rẹ̀ niyẹn.

35 Bayi, a kiyesii wipe awọn ijọ wa loni, gbogbo awọn ijọ wa ni wọn ti gbìn si afẹfẹ, wọn si n ka ìjì. A kò ni awọn ipade adura mọ, a kọ ni awọn isin ti a maa n ni mọ. Ki lo sẹlẹ? A ti rẹ osunwọn silẹ ninu ohun gbogbo. Ẹ woo, awọn ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ paapaa, kun fun awọn obinrin ti wọn ti ge irun ori wọn. Wọn kii gba iyẹn laaye tẹlẹ. Wọn n kun oju, wọn n lo alupayida èékánná, orisirisi awọn nkan; wọn n fi awọn ọkunrin ti o jẹ́ ẹhànnà sibẹ, ati bẹẹ bẹẹ lọ; awọn ti wọn ni iyawo bii mẹta tabi mẹrin, ti wọn si jẹ diakoni; ah, iru òdì wo niyi! Idọti ni! Bawo ni wọn se n se e? Ọlọrun ko ni gba iyẹn laaye ninu ijọ Rẹ, wọn nilati lọ si ijọ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ lati lee wọ inu rẹ. Ẹnikan n bẹru lati sọrọ nipa rẹ, nitori wọn yoo lé wọn jade kuro ninu ẹgbẹ wọn. Ọlọrun, fun wa ni awọn ọkunrin ti kò so mọ́ ohun kankan bikose Ọlọrun ati Ọrọ Rẹ, ti wọn yoo sọ otitọ nipa rẹ̀. Ohun ti a nilo gan-an niyẹn. Ki ni a ti se? A gbin òdì. A ti gbin si afẹfẹ, bayi, a si n ka ìjì.

36 Ẹ kiyesii wipe a n ko wọn jọ papọ bayi fun ijona. Njẹ ẹ kiyesii, Jesu sọ wipe, "Ẹ tete kọ́ kó wọn jọ na, ki e di wọn ni ìtí, lẹyinnaa, ki ẹ si ko gbogbo awọn ìtí yẹn jo, Emi yoo si sun wọn ni ina." Ìtí kekere kan wa ti wọn n pe ni ijọ Eleto, ijọ Onitẹbọmi, ijọ Alagba, ijọ Luther, gbogbo wọn n ko ara wọn jọ papọ sinu Igbimọ Ijọ Agbaye. Ki ni? "Ẹ tete kọ́ kó wọn jọ na." Halleluyah! Njẹ ẹ kiyesii, Ó kọkọ ko awọn èpò jọ na, Ó yà wọn kuro lara alikama, Ó yà wọn sọ̀tọ̀. "Ẹ ko wọn jọ pọ, ki ẹ si fi ina sun wọn." A nilati sun gbogbo wọn ni ina pẹlu awọn idajọ Ọlọrun, nitoripe wọn gbin òdì si aarin awọn eniyan, awọn nkan ti wọn…. Wọn ni afarawe iwa-bi-Ọlọrun, wọn si n sẹ́ agbara rẹ̀, wọn n sẹ́ Ọrọ naa, lati di etutu ẹ̀sìn kan mu ati awọn ẹkọ adamọ ti ẹnikan kì bọ inu rẹ̀, ti wọn n gbiyanju lati fi sinu Ọrọ Ọlọrun. Ko lee sisẹ. Òdì ni.

37 Mo kigbe loni, bi awọn wolii nla atijọ, Amosi, nigbati o wá sinu ilu yẹn, o ni, "Emi kii se wolii, tabi ọmọ wolii. Sugbọn ti kiniun ba bu ramuramu, tani ko ni bẹru!" O ni, "Nigbati Ọlọrun ba sọrọ, tani ko ni sọtẹlẹ." O sọ asọtẹlẹ idajọ lori iran yẹn, o ni, "Ọlọrun ti ẹ sọ wipe ẹ n sin ni yoo pa yin run."

Ẹ fi eleyi sibẹ, o wà lori fanran, ẹ si ranti. Ọlọrun yẹn gan-an ti…. Awọn eniyan wọnyi ti wọn n se akojọ

ikore nla ti Igbimọ Awọn Ijọ Agbaye, ẹ si nilati wọ inu rẹ. Ẹ ko lee takete si i. Yala ki ẹ jade kuro ninu rẹ gẹgẹbi ẹnikọọkan, tabi ki ẹ wọ inu rẹ. Ko si aaye lati duro ni agbedemeji. Yoo jẹ ami ẹranko naa. Ko si ẹni ti o lee rà tabi ti o lee tà, ayafi ẹni ti o ba ni ami naa, tabi ti o ti ni irú òdì naa. Bayi, ẹ takété si i! Ẹ kuro ninu rẹ! Ẹ sa kuro nibẹ! Ẹ rin jinna si i! Ọlọrun ti wọn sọ wipe awọn n sin ni yoo pa wọn run. Ọlọrun ifẹ nla ti ki yoo….

O ni, "Sebi Jesu gbadura wipe ki gbogbo wa jẹ ọkan."

38 Bẹẹni O tun sọ wipe, "Bawo ni ẹ se lee rin papọ, ẹni meji ha lee rin pọ, bikose pe wọn rẹ?" O sọ pe, "ọkan," gẹgẹbi Oun ati Baba se jẹ ọkan. Baba si ni Ọrọ naa, Oun si ni Ọrọ naa ti a fihan. Oun jẹ ọ̀kan pẹlu Baba, nitori Oun ni ifarahan Ọrọ ileri Ọlọrun. Bẹẹ naa ni loni, tabi ni gbogbo ọjọ. Bẹẹ ni, sà. Ọlọrun yẹn, ọ̀kan ni, O si fẹ ki a jẹ ọ̀kan.

Bawo ni eleyi se le jẹ ọ̀kan, eyi n sẹ́ ìbí lati ipasẹ wundia, ati eleyi n sẹ́ iwosan lai lo oogun, ati eleyi, iyẹn, gbogbo wọn si wà ninu ibajẹ kannaa papọ bẹyẹn? Awọn miiran ninu wọn kò tilẹ gbagbọ ninu Ọlọrun - wọn kò gbagbọ wipe Oun ni Ọmọ Ọlọrun; wọn gbagbọ wipe ọmọ Josẹfu ni, wọn wá pè é ni Ọmọ Ọlọrun. Dajudaju. Awọn ibeji ti awọn ijọ Luther, Zwingli, gba iyen gbọ, wipe o kàn jẹ́ eniyan rere kan ni. Awọn ijọ Onimọ-ijinlẹ Kristẹni (Christian Science) sọ wipe wolii kan ni, eniyan kan lasan, ki I se Ọlọrun. Kinla, ti kii ba se Ọlọrun, a jẹ wipe Oun ni ẹlẹtan ti o ga ju ti aye tii ni. Yala ki o jẹ wipe Oun ni Ọlọrun tabi ki o ma jẹ nkankan. Ó wá lati ọrun! Oun ni Ọlọrun, funra Rẹ, ti a sọ di ara laarin wa, ninu ẹni ti Ọmọ Ọlọrun jẹ. Dajudaju, ohun ti Ó jẹ́ niyẹn.

39 Bayi a ri i wipe irú òdì ti wọle wa. A mọ wipe o wà nibi bayi, ko si ẹni ti o lee sọ wipe ko ri bẹẹ. Akiika! Ẹ saa kiyesii. Yoo pa awọn ẹgbẹ yẹn run, awọn ti wọn n sọ wipe awọn n sin Ọlọrun. Ẹ kiyesii.

Ọlọrun gbin Irugbin Rẹ. Mo n danu duro, nitori àkókò ti to lati bẹrẹ ila adura. Ọlọrun gbin Irugbin Rẹ, Irugbin Rẹ si ni Kristi. N o waasu lori iyẹn ni aipẹ yii, ibiti Ọlọrun pinnu lati fi orukọ Rẹ si, bi Oluwa ba fẹ, boya nibi ọ̀kan ninu awọn ipade ounjẹ owurọ ọjọ kan, nigbati mo ba ri aaye diẹ sii. Ẹ wo o, Oun nikan ni ọna lati sa asala. Oun nikan ni ọlọla julọ tootọ. Oun nikan ni Ọlọrun tootọ, ko si ẹlomiran lẹyin Rẹ. "Emi ni Ọlọrun, Emi nikan ni Ọlọrun." O ni, Jesu wipe, "Ofin naa niyi: Ẹ gbọ, Israẹli, Emi ni Oluwa Ọlọrun yin, Ọlọrun kansoso. Emi ni. Eese ti ẹ n wa ẹlomiran? Ẹlomiran yoo wá… mo wá ni Orukọ Baba Mi, ẹyin kò sì gbà mí. sugbọn ẹlomiran yoo wa ni orukọ ara rẹ, oun ni ẹyin yoo si gbà." Wọn si sẹ́ ẹ ni Nikia.

"Se Kristẹni ni ọ?

"Ọmọ ijọ Onitẹbọmi ni mi.

Se Kristẹni ni iwọ?

Ọmọ ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ni mi.

Se Kristeni ni ọ?

Ọmọ ijọ Eleto ni mi,“ orukọ miiran.

40 Sugbọn nigbati ọrọ ba kan orukọ yẹn, Jesu Kristi, wọn rin jinna si i gidigidi, wọn kò fẹ ni nkankan se pẹlu rẹ, nitori Oun ni Ọrọ naa, Ọrọ naa si maa n fi ara Rẹ han. Ẹ kiyesii, ọna abayọ kansoso! Oun ni Ododo Saroni, Bibeli sọ wipe Oun ni. Gbogbo orukọ àpèjẹ́ (ninu Bibeli) Ọlọrun, jẹ ti Jesu Kristi. Oun ni Alfa, Omega, Ibẹrẹ ati Opin; Ẹniti Ó ti wà, Ẹniti Ó wà, ati Ẹniti n bọ̀ wá; Gbòngbò ati Ọmọ Dafidi, Gbòngbò ati Ọmọ Dafidi papọ; Irawọ Owurọ, Ododo Saroni, Itanna Ipado, Alfa, Omega, Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ, gbogbo rẹ ninu Jesu Kristi! Oun ni ẹkunrẹrẹ ifihan Jehofa Ọlọrun ti a sọ di ara lati gbe aarin wa. Ohun ti Ó jẹ gan-an niyẹn!

Oun ni Ododo Saroni. Ki ni wọn n fi ododo Saroni se? Wọn yoo fun-un jade, wọn yoo tẹ ẹ jade, lati mu oorun didun jade ninu rẹ. Ododo roosi ti o rẹwa ni a nilati tẹ mọlẹ lati lee mu oorun didun jade lati ara roosi naa. Iyẹn si jẹ igbe aye ti o dara, ko si igbe aye kan ti a gbe ti o dara to iyẹn ri, sugbọn a nilati fun-un jade ni Kalfari.

41 Se ẹ rii, wọn mu ami-ororo ti ododo Saroni wọn si fi si ara Aaroni, a nilati fi iyẹn ta ami-ororo si i ki o baa lee lọ si iwaju Oluwa ni ibi mimọ naa, ni ibi ìbòjú mimọ. A nilati fi ododo Saroni ta ami-ororo si i, lati wọle lọ fi ẹjẹ wọ́n itẹ aanu lọdọọdun. Ami-ororo yẹn si nilati wà lara rẹ̀, oorun didun si Oluwa, yoo si gbé ẹjẹ ọdọ-aguntan dani niwaju rẹ, lẹyin ti a ti fi ẹjẹ ọdọ-aguntan wọn oun naa lara. Eso pomẹgraneeti ati awọn aago yoo wa lara asọ rẹ, o ni bi o se gbọdọ maa gbe ẹsẹ, ti yoo ma dun, "mimọ, mimọ, mimọ si Oluwa."

42 Ẹ kiyesii, Oun ni Ododo Roosi ti Saroni, oorun didun yẹn, ami-ororo lara awọn eniyan Rẹ̀. O kò lee wá si iwaju Rẹ̀ pẹlu ẹ̀kọ́ àdámọ̀ kankan, tabi ohun miiran, sugbọn a nilati ta ami-ororo si ọ pẹlu ododo roosi ti Saroni yẹn, Ọrọ naa. Oun naa ni Itanna Ipado.

Bayi, bawo ni a se n ri òògùn oorun? A maa n ri òògùn oorun nigbati a ba mu ododo lili ti a fun-un jade, nigbanaa a o ri oogun oorun. Awọn dokita maa n loo ni ile-isẹ ayẹwo wọn. Ti ẹ ba mu ọkunrin kan wa ti ara rẹ ko balẹ, ti ọ̀kàn rẹ pòrúùru, tabi obinrin kan, ti o dabi ẹni wipe ori rẹ ti fẹ daru, ti o n rin lọ soke-sodo, ti o si n pariwo, ti o si n rẹrin laini idi, dokita yoo mu diẹ ninu òògùn oorun lílì rẹ, yoo si fi sii ni apa tabi okùn-ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ nibikan, ara rẹ̀ yoo si balẹ. O ti pari fun igba diẹ niyẹn. Sugbọn ni kete ti oogun oorun yẹn ba ti sisẹ tan, yoo tun pada wa, yoo wa buru ju ti tẹlẹ lọ.

43 Sugbọn mo sọ fun yin, ẹyin ọrẹ, iyẹn kan jẹ apẹẹrẹ ojulowo oogun oorun ti a mu lati ara ododo lili ti ipado ti mo mọ̀. Oun ni Lili ti Ipado, a fun Oun jade ni Kalfari. A paa lara nitori irekọja wa, nipa ina Rẹ ni a mu wa lara da. Ninu iyẹn, ni fifun òdòdó yẹn jade, Oun jẹ òdòdó. Oun ni ododo ti o ga ju ti o tii hu ri, iyẹn ni Lili ti ipado yii, ati ododo Roosi nla ti Saroni. Bayi, Ó so rọ̀ ni asalẹ yii, Ó wà ni agbedemeji aye oun ọrun, mo gbagbọ, Ó wà bẹẹ ni igba yẹn, lati mu ẹ̀sẹ̀ aye kuro, ati lati mu iwosan pada wa si aye. Bibeli si wipe ọkannaa ni Oun lana, loni, ati titi laelae.

44 Ẹyin ọrẹ, nigbati Ọlọrun sọ fun Mose ni aginju, eyi tii se apẹẹrẹ Oun, lati gbe ejò idẹ soke. Idẹ si n se apẹẹrẹ ẹ̀sẹ̀ ti a ti da lẹ́jọ́, ejo n se apẹẹrẹ … ejo idẹ n se apẹẹrẹ ẹsẹ ti a ti da lẹjọ, gẹgẹbi idẹ se jẹ idajọ atọrun wa. Gẹgẹbi pẹpẹ idẹ nibiti a maa fi awọn ẹbọ si. Bẹẹ naa ni Elijah wo òkè, o si sọ pe, "Oju ọrun dabi idẹ" Idajọ atọrun wa lori orilẹ-ede ti ko gbagbọ, ti wọn ti pada sẹyin kuro lọdọ Ọlọrun. Idẹ jẹ apẹẹrẹ idajọ, idajọ atọrun wa. Ejo si se apẹẹrẹ ẹsẹ ti a ti da lẹjọ; Jesu si ni ejo naa ti a sọ di ẹsẹ fun wa, O si gba idajọ Ọlọrun sori ara Rẹ. A paa lara nitori irekọja wa, a naa nitori ẹsẹ wa, ina alaafia wa n bẹ lara Rẹ, ati nipa ina Rẹ ni a mu wa lara da.

Ah, òògùn oorun kún inu apoti òògùn Ọlọrun ni asalẹ yii, fun ọ. Kristẹni ọrẹ, aisan n se ọ, iya si n jẹ ọ. Ah, aarẹ ba ọ, o le ju fun ọ. O kò lee fara daa pupọ mọ, iwọ yoo ya were ninu aye ode oni ti a n gbe yii.

45 Se ẹ gbọ redio "Lifeline" ni asalẹ yii, ohun ti wọn sọ wipe orilẹ-ede Russia sọ, wipe ni ọdun 1955, awọn yoo gba akoso gbogbo aye? Ki iyẹn to lee sẹlẹ, igbasoke nilati kọkọ sẹlẹ na. Bawo ni o se sunmọ tosi to, ẹyin ọre? O ti wa nitosi wa bayi.

Se ẹ ki yoo wa A ni asalẹ yii pẹlu gbogbo ọkan yin. Oun ni ododo Lili ti Ipado, ọkannaa si ni lana, loni ati titi laelae. O wà nibi ni asalẹ yii, lati gbe ara Rẹ soke laarin awọn eniyan Rẹ, gẹgẹbi Mose se gbe ami ẹ̀sẹ̀ naa soke, ti a ti da lẹjọ. Kii sii se ẹsẹ nikan, sugbọn aisan pẹlu. Ẹ ranti, Jesu wipe, "Bi Mose se gbe ejo idẹ soke, bẹẹni a nilati gbe Ọmọ Eniyan soke." Kini Mose gbe e soke fun? Fun ẹsẹ, aigbagbọ, ati fun aisan. A gbe Jesu soke pẹlu, fun ẹsẹ, aisan ati aigbagbọ. Oun jẹ nkan kannaa.

46 Bayi, ni asalẹ yii, ni ọjọ ti a ni òdì nla yii, Jesu Kristi se ileri ni Luuku, wipe ni awọn ọjọ ti o saaju bibọ Oluwa, yoo dabi ọjọ Sodomu, nigbati Ọmọ eniyan yoo fi ara Rẹ han. Bi Ọmọ eniyan se fi ara Rẹ han fun Abrahamu nibẹyẹn; Elohimu, Ọlọrun, ti a sọ di ara laarin awọn eniyan, O si ba Abrahamu gbe nibẹyẹn, O si fi han-an … O sọ ohun ti Sarah n ro (ti o joko si ẹyin re) ninu agọ, ẹniti ko ri ri. O sọ fun-un ohun ti … O si pe orukọ rẹ, "Sarah." "Abrahamu," kii se oruko rẹ Abramu ti o fi bẹrẹ, sugbọn Abrahamu. Kii se Sarai, S-a-r-a-i; sugbọn S-a-r-a-h, "Nibo ni iyawo rẹ, Sarah, wa?"

O ni, "Ó wà ninu agọ lẹyin Rẹ."

O ni, "Emi yoo bẹ yin wo gẹgẹbi àkókò ìyè." O si rẹrin. O sọ pe, "Eese ti o fi rẹrin?"

Bayi, Jesu wipe, "Saaju ki a to ko òdì nla yii jọ lati fi ina sun wọn, wipe Ọmọ eniyan yoo fi ara Rẹ han ni ọna kannaa ti o gba se e ni igba yẹn." Iyẹn si jẹ…. Ki ni? Ó jẹ́ gbigbe soke, lọ́tun, niwaju yin, wipe Jesu Kristi jẹ ọkannaa lana, loni, ati titi laelae. Se ẹ gba a gbọ? Ẹ jẹ ki a tẹriba fun adura nigbanaa.

47 Ọlọrun ọwọn, a fẹran Rẹ. Ọrọ Rẹ jẹ ounjẹ gidi fun wa, Oluwa. A kan saa fẹran rẹ! A n wa laaye nipa rẹ, Oluwa. O dabi ẹni wipe ipá tiwa ko to laelae. A kan saa fẹ lati joko nibi tabili Rẹ, yi Ọrọ Rẹ ka, ki a maa gbadun awọn ibukun naa, Oluwa, nigbati a ba pejọ pọ bi eleyi, awọn arakunrin ati awọn arabinrin ti Ọmọ Ọlọrun ti fi ẹjẹ Rẹ ra, awọn ti o jẹ ẹni irapada nipa ẹjẹ Rẹ. A si wa sibi ni asalẹ yii, Oluwa, a ti ya awọn alẹ yii sọtọ fun gbigba adura fun awọn alaisan. Ati ni ibamu pẹlu Iwe Mimọ, O sọ wipe "nipa ina Rẹ, a ti mu wa lara da." Ko nilo pe ki a gbadura nigbanaa (kiki ki a kan jẹwo awọn ẹsẹ wa ni), nitori nipa ina Rẹ, a ti (ohun ti o ti kọja ni) mu wa lara da. Ah, ọjọ igbala ni eyi! Eyi ni ileri Emmanuẹli! Wipe o jẹ otitọ dajudaju.

O sọ wipe, "Ni igba diẹ sii, aye ki yoo ri Mi mọ, sugbọn ẹyin o ri Mi, nitori Emi (ọrọ-oruko ẹnikan ti "Emi") Emi yoo wa pẹlu yin, ani ninu yin, titi de opin aye." Ati ni opin akoko, igba opin nla yii, O sọ pe saaju ki o to sẹlẹ, yoo ri bi o se ri ki ina to rọ sori Sodomu, ti o si jo aye awọn Keferi run, wipe ifihan Ọmọ eniyan yoo tun wa gẹgẹbi o se ri ni Sodomu. Baba, mase jẹ ki awọn eniyan padanu rẹ.

48 Mo si gbadura, Ọlọrun, gẹgẹbi ọrọ kekere kan, (ti mo ba si ọrọ̀ sọ, dariji mi), wiwọ inu ipele kan lọ, mo fẹran wọn, Oluwa. Mo gbadura wipe wọn ko nii kuna rẹ. Jẹ ki eyi jẹ ọ̀kan ninu awọn alẹ nla naa, Oluwa. Jẹ ki

gbogbo awọn alaisan, awọn ti a n da loro, afọju, ohunkohun ti o ba wa nihin, Oluwa, gba iwosan ni asalẹ yii. Jẹ ki a gba gbogbo ẹlẹsẹ la. Ninu ọkan wọn bayi, ti wọn ba jẹ alaigbagbọ, jẹ ki wọn gba Kristi ni iseju yii. Gba bẹe, Baba. Gbogbo rẹ di ọwọ Rẹ. A fi ara wa le Ọ lọwọ, a fẹ ri Ọ ki O wa si aarin wa.

O si sọ, ni Johannu Mimo 14:12, "Ẹniti o ba gbagbọ ninu Mi, isẹ ti Emi se ni oun naa yoo se pelu." A mo wipe O fi ara Re han fun awọn eniyan, nitori Iwo ni wolii naa ti Mose so wipe yoo dide. Wọn ko ni wolii fun ọgọọgọrun ọdun, irú òdì wa nibi gbogbo, sugbọn sibẹ, a nilati mu Ọrọ Ọlọrun sẹ; nitorinaa Ọrọ naa di ara, bẹẹ naa si ni irú òdì naa pẹlu. Baba, a tun rii loni, irú òdì naa n di ìtí nla kan; a si ri Ọrọ naa ti oun naa n wa bakannaa. Bukun wa ni asalẹ yii, Baba. A fi ara wa le Ọ lọwọ, pẹlu Ọrọ Rẹ. Ohunkohun ti o ba fẹ ki a se, fi wa se e, Oluwa. Ni orukọ Jesu. Amin.

49 [Arabinrin kan sọrọ ni ede miiran. Ibi yii sofo lori fanran.] … tọwọtọwọ gidi. A ko mọ ohun ti O sọ. O lee jẹ wipe O fẹ sọ ohun kan fun wa, nitorina ẹ saa fara balẹ fun igba diẹ. [Ibi yii sofo lori fanran. Arakunrin kan sọ itumọ rẹ.]

Amin. Njẹ ẹ tii ka [ibi yii sofo lori fanran.] iwe mimọ nibi ti ọta ti n bọ, ti gbogbo wọn si ko ara wọn jọ, ọta si jẹ ẹgbẹ ogun nla. Ẹmi Ọlọrun si ba le ọkunrin kan, o si sọ fun-un, o si sọtẹlẹ, o sọ ibi ti wọn gbọdọ lọ duro ni ibùba si, wọn si pa awọn ọta wọn run. O tun ti de bayi. Ibi ti a o ti pa ọta run niyẹn, se ẹ rii, ki a di ọwọ Ọlọrun mu. Ọwọ Ọlọrun ni Kristi, bi ẹ se mọ, Ọrọ naa, nitorinaa ẹ fi eleyi si ọkan yin ni asalẹ yii bi a se n pe ila adura.

50 Mo gbagbọ wipe Billy tun pin kaadi adura loni. B, awọn B, ẹ jẹ ki a mu B-85. A ni mẹẹdogun lalẹ ana. A maa n sa baa fẹ mu mẹẹdogun ni alẹ kọọkan. Ẹ mu kaadi yin dani, a o de ibẹ. Ẹ jẹ ki a gbiyanju bii mẹẹdogun. Aarundinlaadọrun. B, bii Branham, se ẹ mọ. B, aarundinlaadọrun titi de ọgọrun. Ẹ jẹ ki a wo o. Tani o ni B-85, na ọwọ rẹ soke. Se O da ọ loju…. Ah, lẹyin lohun. Ko buru. 85, maa bọ loke.

Bayi, ọmọkunrin mi…. O see se ki awọn alejo wa nihin, wọn le ma mọ bi a se n se eleyi. Ọmọkunrin mi yoo wa, tabi ẹnikan; ti ko ba lee wa, Arakunrin Borders, tabi ẹlomiran. Ọkunrin kan yoo sọkalẹ wa, yoo si mu awọn kaadi wọnyi, ọgọrun wọn, yoo si fi siwaju awọn enyan, yoo si da gbogbo rẹ ru papọ. Nitorinaa, ti o ba fun ọ ni kaadi kan, ko lee sọ fun ọ wipe iwọ yoo wá si ori pẹpẹ, kò mọ iyẹn. Bẹẹni emi naa ko mọ. N o wá ni alẹ ọjọ kan, n o si fa kadi bii mẹwa tabi mẹẹdogun yọ, nibikan laarin awọn kaadi wọnyẹn. Iyẹn ko ni nkankan se pẹlu iwosan rẹ. O lee joko sibẹyẹn. Ẹ wo alẹ ana. Ẹni melo lo wa nibi lalẹ ana, ẹ jẹ ki a ri ọwọ yin? Bi a se wo awọn eniyan san ninu gbogbo ipade yẹn!

51 Bayi, 85 niyẹn, 86, 87, 88, 89, 90. Ẹ jẹ ki wọn maa bọ bayi. B-85, 86, 87, 88, 89, 90. Iyẹn yoo jẹ ọ̀kan. Dajudaju, a nilo ẹnikan… Omiran tun niyi, bẹẹni, iyẹn yoo jẹ ki o pe. 90, 90 titi de 100 bayi. 90, 91, 92, 93, 94, 95, 96, 97, 98, 99.

Ti o ko ba lee rin, ti o ba…. Mo rii wipe a ni awọn meji, kẹkẹ aro mẹta nihin, mo gbagbo wipe awọn mẹrin ni mo ri. Ti o ba ni kaadi adura, ti a ba pe nọmba rẹ, ti o ko si lee rin, saa na ọwọ rẹ soke, a o ti i wa sibi.

52 Ti o ko ba si ni kaadi adura, saa joko sibẹ ki o si maa gbadura, ki o si wipe, "Jesu Oluwa, jẹ ki o kàn mi ni asalẹ yii." Ẹni melo ni o wà nibi ti ko ni kaadi adura, ẹ na ọwọ yin soke. Akiika! O dara. Ẹ jẹ ki a sọ eleyi bayi, mo lero wipe ko da bii ọrọ òdì. Sugbọn obinrin kekere kan wa nigba kan ti ko ni kaadi adura, ki a kuku sọ bẹẹ. O n fi ipa la aarin awọn ero lọ, o ni (ẹ feti silẹ daradara bayi), "Ti mo ba lee fi ọwọ kan asọ Ọkunrin yẹn, a o mu mi lara da." Ẹni melo ni o mọ itan naa? O dara. Ki ni o si se? O fi ọwọ kan-An, o si pada lọ joko. Jesu si yipada, O mọ ibi ti o wa. Se bẹẹ ni? O mọ ohun ti isoro rẹ̀ jẹ́. Se bẹẹ ni? O mọ ohun ti isoro rẹ jẹ, nitorinaa O sọ ohun ti isoro rẹ jẹ fun-un. O si mọ ninu ara rẹ wipe isun ẹjẹ naa ti gbẹ. Se bẹẹ ni? Nitori kini? O ti fi ọwọ kan-An.

53 Bayi, Kristẹni melo ni o wà nibi ni asalẹ yii, ti ó mọ, ni ibamu pẹlu Heberu, iwe Heberu, wipe lọwọlọwọ bayi, Jesu jẹ olori alufaa, Olori Alufaa naa ti O lee bawa kẹdun ninu ailera wa? Se Oun ni? O dara, ti O ba jẹ olori alufaa kannaa, ipo kannaa, olori alufaa, bawo ni yoo se se nigbanaa? Yoo se bi O se se ni igba yẹn. Se ẹ gba iyẹn gbọ? Yoo se bi O se se ni igba yẹn, ti ẹ ba lee gba iyẹn gbọ. O dara. Ẹni melo ni o gba iyẹn gbọ, ẹ na ọwọ yin soke ki ẹ si wipe, "Mo gba a gbọ dajudaju"?

O dara, ki wọn to to ila adura, ẹ jẹ ki a se ila adura ni ita ibẹyẹn. Mo mọ wipe Ọ wà nihin. Mo ni imọlara ifarahan Rẹ, mo si mọ wipe Ó wà nihin. (Se ila adura naa ti setan? Mo fẹ pè ni ita nibẹyẹn.) Ẹyin ẹ saa gbadura, ẹ saa wo ibi yii ki ẹ si gbadura, ẹ saa gbagbọ.

54 Obinrin kekere kan ti o joko si ibi yii ti o n wo mi, o joko si ẹgbẹ obinrin kan ti o wọ awò oju. Se ẹ ko ri iyẹn ti o duro sori obinrin yẹn ni? Wo ibi. Se ẹ rii? Aisan ọkan ni o n da a laamu. Se o gbagbo wipe Ọlọrun yoo wo ọ san? Ti o ba gbagbọ, na ọwọ rẹ soke. Ohun ti o jẹ isoro rẹ niyẹn. Bẹẹ ni. Njẹ ti iyẹn ba jẹ isoro rẹ,

na ọwọ rẹ soke ki awọn eniyan lee rii. Na ọwọ rẹ soke bii… Bayi, o kò níí mọ́ bayi. Igbagbọ rẹ mu ọ lara da.

Ọkanna ni lana, loni, ati titi laelae. Ah, irù òdì n bẹ; sugbọn Jesu Kristi jẹ ọkannaa lana, loni, ati titi laelae. Bayi, ẹ saa maa gbadura, se ẹ rii, ẹ ko nilati wa si oke nibi, ki ẹ lee mọ.

55 Bayi, obinrin kan niyi. Gẹgẹbi o se ye mi, n ko ri i ri ni ọjọ aye mi, ó kàn jẹ́ obinrin kan ti o duro si ibi yii, o si ni kaadi adura, o ko si mọ boya a o pe ọ tabi bẹẹkọ. Ẹnikan saa fun ọ ni kaadi adura, a si pe nọmba rẹ, nitorinaa, iwọ saa maa bọ loke nibi. Se bẹẹ ni? Ko si si bi mo se lee mọ ohun ti o jẹ, ẹni ti o jẹ, ibi ti o ti wa, ohun ti o fẹ, n kò mọ nkankan nipa rẹ. Mo kan saa jẹ ọkunrin, iwọ naa si jẹ obinrin. Bẹẹ ni. Aworan yii farahan ni igba kan ninu Bibeli, Johannu Mimọ, ori 4.

Bayi, o sọ pe, "Ki ni o se, Arakunrin Branham, ni igba yẹn, laipẹ yii." Mo kan wọ inu ipele yẹn ni, se ẹ rii. N kò mọ, se ẹ rii. Oun ni o nilati se e. Emi ko mọ. Bawo ni obinrin ti o wa nibẹyẹn? N ko ri obinrin yẹn ri ni aye mi. O jẹ alejo patapata si mi. Mo gbagbọ wipe obinrin kan ni. Ta ni ẹni ti a wosan laipẹ yii ni aarin ijọ nibẹyẹn? Se iwọ yoo….? A jẹ alejo si ara wa? Ti o ba ri bẹẹ, ju ọwọ soke bi eleyi, se ẹ rii. N ko ri obinrin naa ri. Sugbọn o joko si ibẹyẹn, o gbagbọ. Bayi, o fi ọwọ kan nkankan, abi bẹẹkọ? Ko lee se anfaani lati fi ọwọ kan mi.

56 Sugbọn bayi, se ẹ ko rii wipe Bibeli jẹ Ọrọ Ọlọrun gan-an ni? Ọkannaa ni Oun lana, loni, ati titi laelae. Awa di agọ Ẹmi Mimọ yẹn, eyi tii se Kristi, se ẹ rii. Ojulowo Irugbin niyẹn. Njẹ ti ojulowo Ẹmi Mimọ yẹn ba wọ inu ojulowo Irugbin Ọrọ naa, kii se… Ko kan ni gba apakan rẹ lasan, nitori esu maa n lo iyeṇ. O nilati gba gbogbo rẹ, se ẹ rii, gbogbo ọrọ naa; nitori Ọlọrun kii se ààbọ̀, odidi ni Ọlọrun, se ẹ rii. Ohun ti o si sẹlẹ niyẹn.

Bayi, obinrin kan niyi, n ko rii ri. Jesu ri obinrin kan bi eleyi ni igba kan, boya kii se bakannaa, n ko mọ. O si joko leti kanga kan. O nilo lati lọ si Samaria. A si rii wipe, Samaria wa labẹ oke kan … tabi, O n lọ si Jeriko ni, O si gba Samaria kọja, O si de ilu Sikari kan. O si joko leti kanga, O ran awọn ọmọ ẹyin Rẹ lọ ra ounjẹ.

57 Ẹya eniyan melo ni o wa lori ilẹ aye? Mẹta. Awọn eniyan Hamu, Semu ati Jafeti. Gbogbo wa ti inu Noah wa. Awọn ti o kù ni aye ni a parun ni igba naa. Awọn ẹya eniyan mẹta péré, awọn yen ni Juu, Keferi ati Samaria (eyi tii se aabọ Juu ati aabọ Keferi). Gbogbo ẹya ti o wà lori ilẹ aye niyẹn, se ẹ rii, mẹta pere.

Ohun gbogbo ninu Ọlọrun ni a sọ di pipe ni mẹta. Gẹgẹbi mẹta ti mo n sọ nipa rẹ ni asalẹ yii: ipele mẹta ti irú òdì, ipele mẹta, Ọrọ naa ti a sọ di ara, ati bẹẹ bẹẹ lọ. Se ẹ rii?

Bayi, Ẹni naa ti o ba awọn Juu sọrọ, sọ fun Filipi, nigbati o mu Nataniẹli wá si ibi ti o wà, ti o si wipe, "Mo ri i nigbati o wa labẹ igi." O sọ fun…. Anderu ti mu Peteru wa, O ni, "Simoni ni orukọ rẹ, a o si maa pe ọ ni Peteru lati isisiyi lọ." O ni, "Ọmọ Jona ni ọ." Se ẹ rii. Bayi, Juu ni gbogbo awọn yẹn.

Sugbọn O lọ si ọdọ Keferi … kii se Keferi, sugbọn ara Samaria.

Àkókò awọn Keferi niyi. Ko fi igba kan se iyẹn fun awọn Keferi. Ẹ wa inu iwe mimọ. Laelae. Sugbọn O se ileri, ni Luuku 22 (17), wipe Oun yoo se e ki O to de.

Sugbọn O joko sibẹ yẹn, obinrin kan ti o jẹ ààbọ̀ Juu ati ààbọ̀ Keferi si jade wa. O si wi fun-un pe, "Obinrin yii, fun mi ni omi."

O sọ pe, "Eese, ko yẹ ki o beere iyẹn, o ti pọ ju. Awa jẹ…. Ipinya wa nihin. Juu ni iwọ, ara Samaria ni emi."

O ni, "Sugbọn ti o ba mọ Ẹniti o n ba sọrọ ni, iwọ yoo beere omi lọwọ mi." Ki ni O n se? O n kan ẹmi rẹ̀ lara. Ni kete ti Ó si ti ri ohun ti isoro rẹ̀ jẹ́, O ni ki o lọ pe ọkọ rẹ̀ wa. O sọ wipe oun ko ni ọkọ kankan. O ni, "Otitọ niyẹn, o ti ni marun-un."

58 Ẹ woo bayi, nigbati awọn Farisi ri I ti O se iyẹn, o dara … irú òdì yẹn laarin Ọrọ naa, kini wọn sọ? Wọn ni, "Beelsebuubu ni ọkunrin yii, alafọsẹ." Se ẹ rii?

Jesu si wipe, "Ẹnikẹni ti o ba sọ iru ọrọ yẹn si Ẹmi Mimọ nigbati o ba de lati se nkan kannaa, a ki yoo dari ji i laelae." Irú òdì yin niyẹn. Se ẹ rii? Sugbọn O sọ wipe Oun yoo dari ji wọn ni igba yẹn, nitori Ẹmi Mimọ koi tii de; irubọ naa, Ọdọ Aguntan naa koi tii ku.

Sugbọn obinrin naa ko ro iyẹn. Obinrin naa wipe, "Alagba, mo woye wipe wolii ni Ọ." Wọn ko ni wolii fun ọpọlọpọ ọdun. O ni, "Mo woye wipe wolii ni ọ. Bayi, awa mọ wipe Messiah, ti a n pe ni Kristi, nigbati O ba de, ohun ti yoo se niyẹn."

O dara, ti o ba jẹ wipe ohun ti O se niyẹn, a jẹ wipe Ó jẹ́ okanna lana, loni. Bi o se fi ara Rẹ̀ han nigbanaa niyẹn, se o jẹ nkan kannaa loni? O nilati jẹ bẹẹ! Bayi, obinrin kan ati ọkunrin ni o tun pade bayi. Oun

kọ ni obinrin yẹn. Emi kọ ni Ọkunrin yẹn. Sugbọn sibẹ, Ẹmi Mimọ kannaa wa nibi, O si se ileri wipe isẹ ti O se, a o se nkan kanna ni ọjọ ti a o fi Ọmọ naa eniyan han.

59 Bayi, n kò mọ̀ ọ́ (o si mọ wipe otitọ niyẹn), alejo patapata ni a jẹ, iwọ si duro sibi yii. Boya nkankan n se ọ́, boya ko si si. N ko mọ. Sugbọn ti Jesu Oluwa yoo ba fi han mi, nipa Ẹmi Mimọ Rẹ̀, ohun ti o jẹ isoro rẹ, se iwọ yoo gbagbọ nigbanaa wipe Ọmọ Ọlọrun ni, kii sii se eniyan? Eleyi kan jẹ àgọ́ ara lasan ti Ọlọrun n lo, ẹnikẹni ti O ti yan. O n se eleyi nipa oore-ọfẹ ati iyantẹlẹ. Nitorinaa, iwo saa gbagbọ. Se iwọ yoo se bẹẹ?

Ẹni melo ninu ijọ ni yoo gba a gbọ? Awa mejeeji duro niwaju imọle bayi, wipe a ko pade ri ni aye yii, n ko si mọ ẹni ti obinrin naa jẹ, ohun ti o jẹ, ibi ti o ti wa, ohun ti o fẹ. N ko rii ri laye mi, gẹgẹbi n ko se ri obinrin ti o wà ni ibẹyẹn naa ri laye mi. Sugbọn, se ẹ rii, ohun ti mo n gbiyanju lati jẹ ki ẹ se niyi: ẹ mu irú òdì yẹn kuro lọdọ yin bayi, ki ẹ si gba Ọrọ naa gbọ, nigbati Ọrọ naa ba di ara laarin wa nibi bayi. Ọrọ naa di aaye ninu ara tiwa, iyẹn fi ifarahan Ọlọrun han.

60 Bayi, ki Ọlọrun see fun-un wa. Ohun ti o yẹ ni o n fẹ. Ko bimọ, o n fẹ ọmọ. O ti to bii ọmọ ogoji ọdun. Dajudaju, eleyi see se.

Wọn joko si inu ijọ nibẹyẹn bayi, awọn obinrin ti o ya agan ni gbogbo ọjọ aye wọn, wọn si wa si ibi pẹpẹ bi eleyi, Oluwa si fun wọn ni awọn ọmọ. Ẹyin ti ẹ mọ iyen, ẹ na ọwọ yin soke ni ibẹyẹn. Se ẹ rii? Mo gbe ọmọdebinrin kekere kan ni ijelo, ni ọjọ Sọnde, lẹyin ti mo kuro nibi, ọsan Sọnde; ti iya rẹ yagan, Oluwa si sọrọ. Ọmọbinrin kekere naa, ohun ti o rẹwa julọ, se ó wà nibi? Nibo ni ó wà? Oun niyi nibi, ti o joko si ibẹyẹn, iya rẹ̀ naa joko si ibẹyẹn. Ọmọdebinrin naa niyi funra rẹ̀. Se ẹ rii? Ó jẹ́ Ọrọ ti a sọ lati ọdọ Ọlọrun.

Bayi, se iwọ o gba A gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ? Se o gbagbọ wipe ibukun ti o ni yẹn, ti o ni imọlara rẹ̀ bayi, o jẹ Ọlọrun ti o n dahun? Ti Ọlọrun ba sọ orukọ rẹ fun mi, ki o le ṣọ ọmọ naa ni orukọ, se iwọ yoo gbagbọ? Njẹ, Iyaafin Thompson, o le maa lọ si ile ki o si bi ọmọ rẹ, ti o ba gba a gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ.

61 Se ẹ gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan yin? Ẹ saa ni igbagbọ, ẹ masẹ siyemeji, ẹ saa gba Ọlọrun gbọ. Ọlọrun jẹ Ọlọrun.

Bawo ni, alagba? Mo lero wipe alejo ni a jẹ si ara wa, pẹlu. Igba kansoso ti mo ri ọ ri laye mi, ti mo mọ, ni igba ti o n bọ lati ibẹyẹn. Mo si ro wipe o jẹ ibatan Arakunrin Shakarian … Mushegan, Arakunrin Mushegan, akọrin yẹn, nigbati o n bọ. Lẹyinaa mo rii wipe o n lọ si ibi ila adura. Bayi, mo jẹ alejo si ọ, iwo si jẹ alejo si mi, lọnakọna. Bayi, ti Jesu Oluwa ba sọ ohun kan ti o jẹ fun mi, boya ohun ti o n fẹ, ki a kan sọ bẹẹ; ti o sọ ohun ti o n fẹ fun mi. Bayi, Ó ti fi fun ọ na. Ohun ti o ku ni igbagbọ ti o tó lati gba a gbọ.

Bayi, ẹni melo ni iyẹn yé? Igbagbọ ti o tó lati gbagbọ wipe o ti ri ohun ti o beere gba! Se ẹ rii?

62 Bayi, bayi, ti o bá wà ni oke nibi ti o si n fẹ nkankan, Ó si lee sọ fun mi, ohun ti ifẹ ọkan rẹ jẹ́, nigbanaa o mọ wipe n ko mọ ohun ti ifẹ ọkan rẹ jẹ, njẹ ó nilati jẹ ohun kan nibi yii ti o n se e. Bayi, gẹgẹbi Ọrọ naa, Ó se ileri lati se iyẹn. Ó mọ ero ọkan wọn. Se bẹẹ ni? O dara.

O ni ifẹ okan pupọ lati ri iwosan. Ohun kan, aibalẹ ara n da ọ laamu, ara rẹ ko balẹ rara. Bẹẹ ni. Ohun miiran, o ni ẹyin didun, ẹyin yẹn si ti n dun ọ fun igba diẹ sẹyin, o tilẹ ti se isẹ abẹ lori rẹ. “BAYI NI OLUWA WI” niyẹn. Otitọ ni. Se ẹ rii. Bẹẹ ni. Ohun miiran tun niyi, ifẹ ọkan rẹ ti o jinlẹ ni wipe, o fẹ gba baptisimu Ẹmi Mimọ. Bẹẹ gan-an ni. Wa sihin.

Ọlọrun ọwọn, ni orukọ Jesu Kristi, jẹ ki ọkunrin yii kun fun Ẹmi Mimọ, ki a si dahun ẹbẹ adura rẹ, ni orukọ Jesu. Amin. Saa ni igbagbọ, mase siyemeji.

63 Bawo ni? Mo rò, bi o se ye mi to, wipe a jẹ alejo si ara wa. Ti o ba ri bẹẹ, ki awọn eniyan lee mọ, saa na ọwọ rẹ soke ki wọn lee rii wipe alejo ni a jẹ si ara wa. N ko mọọmọ ri i ri ni gbogbo ọjọ aye mi. Mo lero wipe oun naa ko ri mi ri, ayafi ti o ba jẹ aarin ijọ. Nitori Baba wa Ọrun mọ, Ọrọ Rẹ si niyi nibi yii, wipe n ko mọọmọ ri obinrin naa ri, ni gbogbo ọjọ aye mi. nitorinaa, n ko lee mọ ohun ti o wa sibi fun, n ko si mọ ẹni ti o jẹ, kini, tabi ohunkohun nipa rẹ. N ko lee sọ ohun kan fun ọ.

Ohun kan ni, ẹbun ni ó jẹ́. Ti mo ba lee…. Gẹgẹbi ẹ se gbọ ti mo salaye laipẹ yii. Ki n saa kuro, ki n si gbọ ohun ti Ó n sọ; ohun ti mo ri, mo lee sọ ọ. Ohun ti ko ba sọ, emi ko lee sọ ọ. Ti mo ba sọ funrara mi, yoo kuna. Se ẹ rii? Yoo kuna. Sugbọn ti Oun ba sọ ọ, dajudaju, o tọna. Laelae ko lee… ko kuna ri. Ko si lee kuna, niwọn igba ti o ba jẹ Ọlọrun sibẹ. Se ẹ rii? Se ẹ rii, nitori Ọlọrun ko lee kuna.

64 Sugbọn ti Ọlọrun ba lee sọ ohun ti o fẹ fun mi, ohun ti ifẹ ọkan rẹ jẹ, tabi ohun ti o wa nibi fun, tabi ohun kan ti o ti se, tabi nkankan bẹyẹn, tabi ẹni ti o jẹ, ibi ti o ti wa, tabi ohunkohun ti Ó fẹ́ lati sọ fun mi, iwọ yoo gbagbọ? Ẹ seun.

Ohun akọkọ, o ni isoro pẹlu ẹsẹ̀ rẹ. Ẹsẹ rẹ n yọ ọ lẹnu. Bẹẹ ni. Gbe soke…. O ni aisan obinrin, arun

obinrin. O si tun ni ibeere nla kan ni ọkan rẹ, nitori o sẹsẹ padanu ẹnikan tabi nkankan. Ọmọkunrin kan ni, ọmọkunrin rẹ ti fi ile silẹ, ó salọ, o si fẹ ki n gbadura wipe ki ó pada.

Ọlọrun ọrun, ran ọmọ rẹ̀ si i. Jẹ ki Ẹmi Mimọ da ọmọkunrin yẹn duro loju ọna ni asalẹ yii, Oluwa, daa pada si ọdọ iya rẹ̀. Ni orukọ Jesu. Amin.

Ẹniti o mọ̀, yoo daa pada fun ọ. Ma daamu. Sa gbagbọ bayi, mase siyemeji. Saa ni igbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ. Iwọ gbagbọ, Ọlọrun yoo se eyi ti o kù.

65 Bayi, awọn imọ-ẹmi-yatọ mẹta tabi mẹrin yẹn, ohunkohun ti o jẹ, se ẹ rii, mo saa n lọ titi ti n ko fi riran mọ. N ko lee salaye iyẹn, ko si ọna lati salaye rẹ. O sọ pe, “Iyẹn ni wipe, iyẹn nikan le ju bi o se waasu fun iseju marundinlaadọta tabi ju bẹẹ lọ, se o ro bẹẹ?” Bẹẹni, sà. Ti ó bá jẹ́ wakati mẹta, ko lee le to iyẹn.

Obinrin kan fi ọwọ kan asọ Jesu Oluwa wa. Awọn eniyan wọnyẹn ko si fi ọwọ kan mi. Eese, obinrin ti o wà nibi niyi, ẹ wo o, o lee…. O lee fi ọwọ kan gbogbo ara mi, iyẹn ko ni se nkankan. Eniyan lasan ni mi. Sugbọn o nilati fi ọwọ kan Oun. Ati emi, nipa ẹbun kan,…. O saa … ki n kan jọwọ gbogbo ara mi, n o kan sọ ohun ti mo ba ri. Se ẹ rii? Ko ju bẹẹ lọ. Se ẹ rii, fifi ọwọ kan mi kò jẹ́ nkankan, sugbọn o fi ọwọ kan Jesu nipasẹ mi. Bi obinrin yẹn se fi ọwọ kan Ọlọrun nipasẹ Jesu niyẹn, nigbati…. Ko mọ ohun ti o n se e. O kan saa fi ọwọ kan asọ Rẹ ni, o si lọ joko. O si wipe, “Ta ni o fi ọwọ kan mi?”

Awọn aposteli si wipe, “Eese, gbogbo eniyan ni o n fi ọwọ kan O. Eese ti o fi sọ bẹyẹn?”

O ni, “Sugbọn mo woye wipe asẹ ti ara mi jade.”

Bayi, ẹ mọ ohun ti asẹ jẹ? Okun. O kaare nitori obinrin kan fi ọwọ kan-an, Oun si jẹ Ọmọ Ọlọrun. Emi ẹlẹsẹ ti a fi oore-ọfẹ gbala nkọ. Njẹ ẹ mọ idi ti o fi pọ si i? Nitori O wipe, “Awọn ohun ti Mo n se wọnyi, ni ẹyin naa yoo se pẹlu. Pupọ ju eyi ni ẹyin yoo se, nitori Emi n lọ si ọdọ Baba Mi.” “Giga ju,” ni o sọ nibẹyẹn, sugbọn itumọ ede Giriki tootọ ni “pupọ ju eyi ni ẹyin yoo se.”

66 Bayi, n ko mọ obinrin naa. N ko mọ nkankan nipa rẹ. O jẹ ajeji si mi bi awọn eniyan yooku naa se jẹ. A jẹ ajeji si ara wa. Ki awọn eniyan baa lee mọ ọ, o lee na ọwọ rẹ soke, wipe a jẹ ajeji. Bayi, Ọmọ Ọlọrun, ti Ó ba pade obinrin kan nigba kan ni ibi ti ó jẹ́ gbangba bi eleyi, leti kanga, ti Ó si ba a sọrọ fun igba diẹ, O si mọ ibi ti isoro rẹ wà, O si sọ isoro rẹ fun-un. O si mọ nipa iyẹn, wipe Messiah naa niyẹn. Bayi ti o ti fi ọwọ kan mi, mo ti fi ọwọ kan ọ, nkankan ko si sẹlẹ. Sugbọn ti igbagbọ mi (nipa ẹbun kan) ati igbagbọ rẹ (nipa gbigbagbọ ninu rẹ) ba lee fi ọwọ kan Oun, ti O si lee sọrọ nipasẹ wa, nipasẹ mi si ọ, nigbanaa o mọ wipe Ó wà nibi bi Ó se wa leti kanga yẹn ni Sikari. Se ẹ rii? Ọkannaa ni lana, loni, ati titi laelae. Se ẹ gba iyẹn gbọ?

O ni ọpọlọpọ isoro, ọpọlọpọ idaamu, oniruuru. Ọkan ninu awọn nkan pataki ti o fẹ ki a gbadura fun ni aromọleegun. Bẹẹ ni. Ko ri bẹẹ bi? Aromọleegun ti n ka ọ ko. Nigbati o ba gbe ọwọ rẹ soke….

67 O si maa n rọra rin diẹdiẹ, bi mo se ranti to. Ẹ duro diẹ na, boya a o sọ nkan miiran ti yoo mu… Ni ita nibi yii, a n ni imọlara awọn nkan; awọn eniyan, se ẹ mọ, bii igba ti eemi ba bi lu u. Wọn ni, “Eese, o kan ro iyẹn ni,” tabi, se ẹ mo iru nkan bẹyẹn.

Sugbọn, o dabi ẹni wipe eniyan daradara ni ọ, saa ba mi sọrọ fun iseju diẹ. Jẹ ki a duro sibi diẹ na, nitori mo ro wipe nkan miiran n bẹ ni ọkan rẹ ti o fẹ lati ọdọ Ọlọrun. Bayi, emi ko lee dahun adura rẹ, sugbọn Oun lee se e…. Nitori, ti o ba gba a gbọ, a ti dahun rẹ na. Sugbọn ti o ba sẹsẹ fẹ gbagbọ; lati mu ọ gbagbọ. Bayi, mo sọ fun ọ, ó nii se pẹlu ẹnikan ti o fẹran ti ko si nibi, iyẹn ni arakunrin kan, arakunrin naa ko si si ni ilu yii. O wa ni ilu olomi kan, ibi ti adagun odo pọ si. Mo lee sọ wipe boya bii Michigan tabi ibi kan…. Michigan ni ibẹ. Aisan asekupani kan ni o si n daa loro, iyẹn ni aisan kidinrin ti ko gboogun, ti o n daa laamu. Bẹẹ ni, abi bẹẹkọ? “BAYI NI OLUWA WI” niyẹn. Bayi, asọ ilewọ ti o wa ni ọwọ rẹ ti o na soke si Ọlọrun, fi iyẹn ransẹ si arakunrin rẹ ki o si sọ fun-un wipe ki o mase siyemeji, sugbọn ki o gbagbọ, a o si wo o san ti o ba lee gba a gbọ.

68 Se ẹ gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan yin? Se ẹ rii, nigbanaa, ti ẹ ba gbagbọ, ohun kan ni o ku lati se, iyẹn ni wipe, ki ẹ gba a patapata. Se bẹẹ ni?

Bayi o sọ pe, “O n wo awọn eniyan yẹn ni. Ohun ti o n se niyẹn, o n wo wọn.” E ti ri iyẹn pupọ!

Sugbọn ki ẹ lee mọ eyi…. Obinrin ti o wà nibi yii, goke wa sihin, arabinrin ti o wà nibi yii, alaisan, tabi ẹnikẹni ti o jẹ. Emi ko wo o. Se o gbagbọ wipe Ọlọrun lee fi ohun ti o jẹ isoro rẹ han mi? Na ọwọ rẹ soke, ti o ba gbagbọ, arabinrin ti o wa nibi yii, obinrin ti o wa nibi yii, alaisan naa. O dara nigbanaa, ti o ba lee gba iyẹn gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, aisan ailemidada yẹn ko ni da ọ laamu mọ. O dara, maa lọ si ile ki o si gba a gbọ, ti iwọ yoo ba se bẹẹ.

69 Ẹ wo o, oun niyi. Se ẹ rii, ẹ wo ibi, iran naa wa nibẹ laibikita ohun ti o sẹle. Amin! Se ẹ ko lee rii ni? O pe

bi Ọlọrun ti pé!

Se iwọ naa gbagbọ pẹlu? Aisan ailemidada lee fi iwọ naa silẹ, abi bẹẹkọ? Se o gbagbọ wipe yoo fi ọ silẹ? O dara, lọ sọ fun Jesu Oluwa wipe o gba A gbọ.

Lọjọ kan, iwọ yoo maa gbe ọpa kan kiri ti arun arọmọleegun yẹn ba sọ ọ di arọ, sugbọn ko nii se e. O kò gbagbọ wipe bẹẹ ni, abi? Se o gbagbọ wipe ara re yoo da? Maa lọ, Jesu Kristi mu ọ lara da.

Aisan ọkan maa n pa awọn eniyan, sugbọn ko nilo lati pa iwọ. Se o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo o san fun ọ, ki O si mu ọ lara da? Maa lọ, ki o si gba a gbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, sọ pe, “Mo gbagbọ fun-un nitootọ.”

70 Se o maa n sọ ede oyinbo? Se o gbọ ede oyinbo? Ki ẹnikan wa. [Ogbufọ kan wa siwaju.] O dara. Se iwọ yoo sọ ohun ti mo sọ fun-un? Sọ fun-un wipe ti o ba lee gbagbọ, inu rirun yẹn yoo fi i silẹ. Se oun yoo gba a gbọ? Ẹyin didun yẹn yoo fi ọ silẹ pẹlu, bayi, o lee maa lọ ki a si mu ọ larada.

Bawo ni? Se o gbagbọ?

Ọkunrin ti o joko si ibẹyẹn pẹlu ẹyin didun, ti o n wo mi nigbati mo sọ iyẹn. A lee wo oun naa san pẹlu, ti o ba gba a gbọ, sà. O dara, sà.

Obinrin ti o joko si ẹgbẹ rẹ nibẹyẹn, o ni aisan ni ọrùn rẹ, abi bẹẹkọ, arabinrin? Se o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo ọ san? O fẹ gbe ọwọ le ọmọdekunrin yẹn ki o lee ri iwosan fun orunkun rẹ̀ pẹlu. Se o gba a gbọ? O ni aisan obinrin, aisan obinrin, o kò ni i mọ bayi. Igbagbọ rẹ wo ọ san, o si mu ọ lara da.

71 Se ẹ gba Jesu Kristi gbọ, ọkannaa lana, loni, ati titi laelae? Nigbanaa, ẹ jẹ ki a gbe ọwọ wa le ẹnikeji wa ki a si gba adura igbagbọ yii, olukuluku wa, ki a gba adura igbagbọ.

Ọlọrun ọwọn, nigbati ifarahan Rẹ si bò wá mọlẹ, ti a ri Ọ ti O n rin laarin ijọ, ti O si n mu awọn alaisan lara da nibi gbogbo. Iwọ ni Ọlọrun. Mo gbadura wipe ki O wo gbogbo ijọ yii san. Jẹ ki eemi Ọlọrun sọkalẹ ni ọ̀tun sinu ọkan wọn, si jẹ ki wọn mọ wipe akoko n tan lọ. Igba diẹ sii ni a ni lati wa nihin yii, lẹyinnaa a o wà pẹlu Ẹni naa ti a fẹran. Jẹ ki ifarahan Rẹ mu iwosan wa fun olukuluku bayi.

A da Satani lẹbi, a da gbogbo isẹ rẹ̀ lẹbi. Ni orukọ Jesu Kristi, Satani, jade kuro lọdọ awọn eniyan yii.

Gbogbo ẹyin ti ẹ o gba A gbọ bayi, ti ẹ si gba iwosan yin, ẹ dide duro lori ẹsẹ yin, ki ẹ sọ pe, “Mo dide duro bayi lati gba iwosan mi. Mo gba a gbọ.” Laibikita fun ipo ti o wa, ti o ba gba a gbọ nitootọ, dide duro lori ẹsẹ rẹ. Bayi, na ọwọ rẹ soke, ki o sọ pe, “O seun, Jesu Oluwa, wipe O wo mi san.” Ki Ọlọrun wa pẹlu yin.

MESSAGE hub online

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu
William Marrion Branham
"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7